# SS 2 FIRST TERM NOTE 2026
## SCHEME OF WORK

**Week 1- Ọ̀sẹ̀ Kìn-ín-ní**:
Èdè: àròkọ Aṣàríyànjiyàn
Àlàyé lórí àròkọ aṣàríyànjiyàn, àpẹẹrẹ orí-ọ̀rọ̀ fún àròkọ aṣàríyànjiyàn, ìgbésẹ̀ àròkọ aṣàríyànjiyàn, àpẹeẹ àròkọ aṣàríyànjiyàn.

**Week 2 - Ọ̀sẹ̀ Kejì**:
Lítíréṣọ̀: Àtúpalẹ̀ ìwé ìtàn àròsọ.
Ìtàn ní ṣókí, Àhunpọ̀ ìtàn, ọgbọ́n ìsọ̀tàn, ibùdó ìtàn, ẹ̀dá ìtàn, ìjẹyọ àṣà, ìlò èdè, kókó ẹ̀kọ́.

**Week 3 - Ọ̀sẹ̀ Kẹta**
Àṣà: Àṣà Ìsìnkú nílẹ̀ Yorùbá.
Àlàyé tó jẹmọ́ àṣà ìsìnkú, oríṣi ikú tó ń pa ènìyàn, orò tó jẹmọ́ òkú, ìtúfọ̀, adìrẹ ìrànà, ìtọ́jú òkú, títẹ̀ òkú ní ìtẹ́ ẹ̀yẹ, eégún òkú, òkú ríró, bí a ti ń sin òkú abàmì ẹ̀dá.

**Week 4: Ọ̀sẹ̀ Kẹrin**
Èdè: Gbólóhùn Èdè Yorùbá.
Oríkì Gbólóhùn, Àpẹẹrẹ gbólóhùn, Ìsọ̀rí gbólóhùn nípa ìhun (gbólóhùn abọ́dé, gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe, gbólóhùn alákànpọ̀)

**Week 5 - Ọ̀sẹ̀ Karùn-ún**
Àṣà: Eré Ìdárayá nílẹ̀ Yorùbá.
Ìtumọ̀ eré ìdárayá, oríṣi eré ìdárayá, eré ìdárayá abẹ́lé, eré ìdárayá ìta-gbangba, àǹfààní àti àléébù eré ìdárayá.

**Week 6 - Ọ̀sẹ̀ Kẹfà**
ìtẹ̀síwájú ìwé ìtàn àròsọ.
Kókó ìtàn àti ohun tí ìtàn dálé lórí, àwọn ẹ̀dạ ìtàn, àṣà tó súyọ, ìlò èdè, kókó ẹ̀kọ́.

**Week 7 –Ọ̀sẹ̀ Keje**
Ètò Ìṣèlú nílẹ̀ Yorùbá.

Ètò agboolé, ojúṣe baálé, ojúṣe ìyáálé, ojúṣe obìnrin ilé, ètò oyè jíjẹ, oyè ìdílé, oyè ìfidánilọ́lá, oyè ẹ̀sìn, oyè ògbóni, oyè ológun.

**Week 8 - Ọ̀sẹ̀ kẹjọ**

Àròkọ oníròyìn.

Ìtumọ̀ àròkọ oníròyìn, àpẹẹrẹ orí-ọ̀rọ̀ fún àròkọ oníròyìn, ìgbésẹ̀ àròkọ oníróyìn, àpẹẹrẹ àròkọ oníròyìn.

**Week 9 - Ọ̀sẹ̀ Kẹsàn-án**

Ètò ọrọ̀ ajé(ìpolówó ọjà) nílẹ̀ Yorùbá.

Àlàyé lórí ìpolówó ọjà, ìpolówó ọjà láyé àtijọ́, ìpolówó ọjà láyé òde òní.

**Week 10 - Ọ̀sẹ̀ Kẹwàá**

Ọ̀rọ̀ àyálò.

Àlàyé lórí ọ̀rọ̀ àyálò, òfin tí ó de ọ̀rọ̀ àyálò, okùnfà ọ̀rọ̀ àyálò, orísịi ọ̀rọ̀ àyálò.

**Week 11 - Ọ̀sẹ̀ Kọkànlá**

Èdè: Ọ̀rọ̀ àgbàsọ (afọ̀ aṣafọ̀ àti afọ̀ agbàrán)

Ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ àgbàsọ, àlàyé lórí afọ̀ aṣafọ̀ àti afọ̀ agbàrán, Àwọn atọ́ka ọ̀rọ̀ àgbàsọ, àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí ó máa ń jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ àgbàsọ

## ỌSẸ̀ KÌN-ÍN-NÍ – WEEK ONE
## ÀRÒKỌ ALÁRÌÍYÀJIYÀN

Àrokọ alárìíyàjiyan ni àròkọ tí ó máa ń ní abala méjì. Irú àròkọ báyìí máa ń mú iyàn jíjà dánî. Mo fara mọ́ ọn, n kò fara mọ́ ọn, bẹ́ẹ̀ni tàbí bẹ́ẹ̀kọ́ máa ń wáyé nínú àròkọ yìí. Bí ó bá jẹ́ ọlọ́rọ̀ ẹnu ni alároko gbọ́dọ̀ fi ara mọ́ abala kan kí ó sì tako abala kejì. Ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ kíkiọ sílẹ̀ ni alároko gbọ́dọ̀ ṣọ̀tún ṣòsì kí ó sì fara mọ́ apá kan nígbẹ̀yìn.

**ÀPẸẸRẸ ORÍ-ỌRỌ̀ FÚN ÀRÒKỌ ALÁRÌÍYÀJIYÀN**

1. Ọmọ bẹẹrẹ òṣì bẹẹrẹ.
2. Owó lẹ̀gbọ́n ọmọ làbúrò.
3. Iṣẹ́ àgbẹ̀ pé ju iṣẹ́ dókítà lọ.
4. Ilé-ẹ̀kọ́ aládàáni sàn ju ilé-ẹ̀kọ́ ìjọba lọ.
5. Kò yẹ kì akẹ́kọ̀ọ́ girama máa lo ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀.
6. Ìjọba ológun sàn ju ìjọba alàgbádá lọ.
7. Kí ènìyàn kọ́kọ́ kọ́ ilé dára ju kí ènìyàn kọ́kọ́ ram ọ́tò lọ.
8. Iṣẹ́ olùkọ́ dárá ju iṣẹ́ àgbẹ̀ lọ.
9. Kí ọkùnrin ní ìyàwó kan sàn ju oníyàwó púpọ̀ lọ.
10. Ìgbé ayé àtijọ́ dára ju ìgbé ayé òde òní lọ.

**ÌGBÉSẸ̀ ÀRÒKỌ ALÁRÌÍYÀNJIYÀN**

1. Orí- ọ̀rọ̀
2. Ìfáàrá
3. Kókó àròkọ
4. Ìgúnlẹ̀ / ìkádìí.

### ÀPẸẸRẸ ÀRÒKỌ ALÁRÌÍYÀNJIYÀN

**<u>Iṣé Àgbẹ̀ Pé Ju Iṣẹ́ Dókítà Lọ</u>**

Àwọn àgbe ló ń gbin iṣu, àgbàdo, ẹ̀gẹ́, ata, ọ̀gẹ̀dẹ̀ àti ohun gbogbo tí ẹnu ń jẹ. Àwọn náà ló ń sin ohun ọ̀sìn bíi adìẹ, ewúrẹ́, àgùntàn pẹ̀lú àwọn ohun ọ̀sìn yòókù. Àwọn dókítà ló ń tọjú aláìsàn yálà ilé ìwòsàn ìjọba tàbí aládàáni.
Oríṣiríṣi ọ̀nà ni iṣẹ́ àgbẹ̀ gbà dára ju iṣẹ́ dókítà lọ. Ní ọ̀nà kìn-ín-ní, àwọn àgbẹ̀ ló ń gbin ohun gbogbo tí ẹnu ń jẹ. Bí kò bá sí àgbẹ̀ ebi ni yóò pa dókítà kú. Ní ọnà kejì, iṣẹ́ àgbẹ̀ kò gba ìwé kíkà àkà-kú-akátá kí ènìyàn tó mọ̀ nípa rẹ̀. Bákan náà ni kò gba ìnáwó rẹpẹtẹ bí iṣẹ́ dókítà.

Ní ọ̀nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, kíkọ́ iṣẹ́ àgbẹ̀ kò gba àkókò rárá kò sì nira bí iṣẹ́ dókítà. Ènìyàn nílò tó ọdún méje sí méjọ kí ènìyàn tó lè di dókítà. Ṣùgbọ́n iṣẹ́ àgbẹ̀ kò lè gba ènìyàn tó ọdún kan. Iṣẹ́ àjogúnbá ni iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ àtìrandíran àwọn baba-ńlá wa ni. Ènìyàn lè fi iṣẹ́ àgbẹ̀ lé ọmọ lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n èyí kò ṣe é ṣe nínú iṣẹ́ dókítà.

Àwọn àgbẹ̀ kìí dúró de ìparí oṣù kí wọ́n tó rí owó ná. Lóòrè kóòrè ni owó máa ń wọlé sí ọwọ àwọn àgbẹ̀, owó sì pọ̀ nídìí iṣẹ́ àgbẹ̀ ju iṣẹ́ dókítà lọ.

Iṣẹ́ dókítà náà ní àwọn àǹfààní tirẹ̀. Bí kò bá sí dókítà àìsàn ni ìbá pa gbogbo ayé. Iṣẹ́ dókítà fi ènìyàn lọ́kàn balẹ̀ ju iṣẹ́ àgbẹ̀ lọ. Ọ̀gá tà ọ̀gá kò tà owó aláàárù gbọ́dọ̀ pé nídìí iṣẹ́ dókítà. Iṣẹ́ dókítà kìí ṣe iṣẹ́ ìdọ̀tí bí iṣẹ́ àgbẹ̀.

Pẹ̀lú gbogbo àlàyé wọ̀nyí, nínú èrò tèmi, èmi gbà pé iṣẹ́ àgbẹ̀ pé ju iṣẹ́ dókítà lọ.

## OWÓ LẸ̀GBỌ́N ỌMỌ LÀBÚRÒ

Kò sí òtítọ́ nínú ọ̀rọ̀ yìí pé “Owó lẹ̀gbọ́n ọmọ làbúrò”. Bí ènìyàn lówó lọ́wọ́ bíi ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ bí kò bá bí ọmọ owó olówó ni. Bí ènìyàn ra ọkọ̀ bọ̀gìnnìn bọ̀gìnnì bí kò bá bí ọmọ ọkọ̀ ọlọ́kọ̀ ni. Bí ènìyàn sì kọ́ àìmọye ilé tí kò bá bí ọmọ ilé onílé ni. Ọmọ ṣe pàtàkì, ọmọ ṣe kókó. Kí Elédùà jẹ́ kí á rí ọmọ pè rán níṣẹ́.
Àìmọye ọ̀nà ni ọmọ gbà ṣe pàtàkì. Ọmọ ẹni ni ààrọ̀ ẹni. Bí a bá dàgbà, tí a dògbó tí a rebi àgbà rè, ọmọ ẹni ni wolé deni. Bí ènìyàn bá bí ọmọ sáyé irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò lè kú àkúrun. Bí ènìyàn kò bá lówó ṣùgbọ́n tí ó gbìyànjú láti tọ́ àwọn ọmọ rẹ̀, tí irú àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ bá là tí wọ́n lu àlùyọ láyé ọlá àti ọlà wọn a máa ran àwọn òbí wọn.

Bí ènìyàn kò bá ní owó lọ́wọ́ kí ó gbìyànjú kí ó kọ́ àwọn ọmọ rẹ̀ nítorí ọmọ tí a kò kọ́ ni yóò gbé ilé tí a kọ́ tà. Bí ènìyàn kò bá bí ọmọ láyé, ohun ẹ̀gàn àti ìtìjú ńlá ni. Ọmọ ní wolé deni bí a kò bá sí nílé. Ní ilẹ̀ Yorùbá orúkọ ọmọ ni a fi ń pe òbí. Wọ́n á ní ìyá lágbájá, bàbá tàmọ̀dù. A kìí fi orúkọ owó pe olówó. Àwọn Yorùbá máa ń sọ pé “Ẹni tó bímọ ọmọ ló máa sín ín, ẹni tí kò sí bí ọmọ, ọmọ náà ló máa sin ín”. Bí ẹni tí kò bí ọmọ bá kú, ọmọ ọlọ́mọ ni yóò sin irú ẹni bẹ́ẹ̀. Kínní yìí kinní mi ni ó sàn ju kiní yìí kinní wa ni. Ọmọ kò ṣe é pààrọ̀.

Owó náà ní àǹfààní tirẹ̀. Owó la fií kọ́lé owó la fií tọ́ ọmọ. Bí kò bá sí owó kí ni a fẹ́ fi tọ́ ọmọ ọ̀hún? Olowó ló layé, olówó ló lohun gbogbo. Bàbá rere bàbá kẹ̀, owó ló ń jẹ́ bẹ́ẹ̀. Owó a máa sọ ènì di ẹni iyì, ẹni pàtàkì láwùjọ. Owó ni kókó. Olówó layé mọ̀. Owó ló ń sọ baba dẹrú, owó ló ń sọ ọmọ di baba.

Bí owó ṣe wá ṣe pàtàkì tó yìí èmi kò gbà pé owó lẹ̀gbọ́n bíkọ̀ṣe àbúrò. Nítorí ìdí èyí ọmọ ni ẹ̀gbọ́n owó ni àbúrò. Kí Olódùmarè má fi ọmọ pọ́n wa ójú.

**Iṣẹ́ Ṣíṣe – Class Work**

1. Àròkọ alárìíyànjiyàn ni ___ essay
   A. Argumentative
   B. Narrative
   C. Descriptive
2. Èwo nínú àwọn wọ̀nyí ni àpẹẹrẹ orí-ọ̀rọ̀ fún àròkọ alárìíyànjiyàn?
   A. Irú ilé tí mo fẹ́ kọ́.
   B. Iṣẹ́ olùkọ́ pé ju iṣẹ́ dókítà lọ
   C. Ìjàǹbá ọkọ̀ kan tó ṣojú mi.
3. Mo fara mọ́ ọn, n kò fara mọ́ ọn, má a ń jẹyọ nínú àròkọ ____
   A. Ajẹmọ́-ìṣípayá
   B. Oníròyìn
   C. Alárìíyànjiyàn.
4. Ìgbéṣẹ̀ àkọ́kọ́ nínú àròkọ alárìíyànjiyàn ni
   A. Ìfáàrá
   B. Orí-ọ̀rọ̀
   C. Ìkádìí.
5. Èwo ni kò sí nínú àròkọ alárìíyànjiyàn?
   A. Orí-ọ̀rọ̀
   B. Ìfáàrá
   C. Àdírẹ́sì.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá – Assignment**

1. Kọ àròkọ bí ojú ewé kan lórí, “Iṣẹ́ olùkọ́ pé ju iṣẹ́ àgbẹ̀ lọ”

**Week 2 – Òsè Kejì: Ìtúpalẹ̀ ìwé ìtàn àròsọ**

**<u>Ogún Ọmọdé</u> láti ọwọ́ Akinwùmí Ìṣọ̀lá**

**Ìtàn Ní Ṣókí**

**Orí Kìn-ín-ní: Àkókò Ìsinmi**

Bí Délọdún, Àkànmú àti iyìọ̀lá ṣe jẹun ọsán tán ní ọjọ́ yìí wọ́n lọ bá Dọlápọ̀ kí ó jẹ́ kí àwọn lọ ṣeré nínú oko. Iyìọ̀lá àti Dọlápọ̀ bẹ̀rẹ̀ sí bá ara wọn jà ní ojú ọ̀nà. Fọlá bá wọn ní ibi tí wọ́n ti ń ba ara wọn jà ó sì gbìyànjú láti là wọ́n. Délọdún ta rọ́bà rẹ̀ mọ́ Fọlá ní ìpàkọ́. Fọlá kígbe tòò ó sì bẹ̀rẹ̀ sí lé wọn kiri. Ọwọ́ rẹ̀ kò tẹ̀ wọ́n ó sì pinnu láti lọ fi ẹjọ́ wọn sùn.

Lẹ́yìn èyí wọ́n gé igi ìbẹ́pẹ wọ́n fi ṣe ọkọ̀ wọ́n sì ń fi wọ́ ara wọn kiri. Nígbà tí èyí sú wọn, wọ́n tún ṣe firidùgbẹ̀ wọ́n ń rọ̀ dirodiro lórí okùn. Orí eré yìí ni wọ́n wà ti baálé ti wá fi ẹgba tú wọn ká. Ilẹ̀ ti ṣú kí kóówá wọn tó délé ní ọjọ́ yìí. Délọdún kò wá igi tí o yẹ kí ó wá, èyí mú kí ó lọ jí igi kó ní ilé àwọn Jíire. Nígbà tí ó dé ilé ẹ̀rù ń bàá láti wọ ilé ó lérò pé wọn yóò bá òun wí fún pípẹ́ tí ó pẹ́ wọlé. Ó sáré ki oúnjẹ rẹ̀ mọ́lẹ̀ ó sì sálọ sí ilé ìyá àgbà. Bí ó ti jẹun tán ni ìyá rẹ̀ yọ ẹgba dé láti nàn án fún ìwà tí ó hù. Ṣùgbọ́n ìyá àgbà kò jẹ́ kí ìyá rẹ̀ nàn án. Kí wọ́n tó sùn ní ọjọ́ yìí wọ́n sọ̀rọ̀ nípa ọkọ àfẹ́sọ́nà Àyọ̀ká, ṣùgbọ́n inú Àyọ̀ká kò dùn sí ọkọ tí àwọn òbí rẹ̀ yàn fún un. Inú Délọdún náà kò dùn sí ọkùnrin náà kò sì fẹ́ kí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ fẹ́ ẹ.

Bí ilẹ̀ ọjọ́ kejì ṣe mọ́ ni ẹ̀gbọ́n rẹ̀ tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Bọ̀dé ní kí ó tẹ̀lé òun lọ sí oko, àmọ́ ìyá rẹ̀ ní kí ó bá òun ṣe tàràgá tí wọ́n máa ń sá nǹkan sí. Ibi tí òun àti Iyìọ̀lá ti ń gé igi akòko àti ọ̀wà ni wọ́n ti pa ejò sóóró. Wọ́n di ejò náà ní ewé gbòdògì wọ́n pè é ní àgbáyun wọ́n sì gbé e fún Ejiníkẹ̀ẹ́. Dípò àgbáyun ejò ni Ejiníkẹ̀ẹ́ bá nínú ewé. Ẹ̀rù bà á, ó sọ ejò nù. Ó sì fi igbe bọ ẹnu. Gbogbo ènìyàn pé lé wọn lórí, wọ́n ń bú Iyìọ̀lá àti Délọdún fún ìwà ìkà tí wọ́n hù. Ní alẹ́ ọjọ́ yìí ni ìyá Ejiníkẹ̀ẹ́ àti Fọlá lọ́ fi ẹjọ́ Iyìọ̀lá àti Délọdún sun àwọn òbí wọn. Àwọn méjèèjì ni wọ́n rí ìyà he ní ọjọ́ náà.

Ní ọjọ́ kan àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin dẹ ìgbẹ́ lọ. Àkànmú àti Dọlápọ̀ ń da igbó sí Iyìọ̀lá àti Délọdún. Wọ́n pa eku àgó méjì àti ẹmọ́ kan.

Ibi tí wọ́n ti ń da igbó mìíràn ni yèrèpè ti gbọ̀n jó Àkànmú àti Dọlápọ̀. Àwọn méjèèjì bẹ̀rẹ̀ sí í kígbe, wọ́n sáré lọ sí odò láti lọ wẹ̀. Ojú ọ̀nà odò ni wọ́n ti pàdé Ẹ̀jìníkẹ̀ẹ́ àti ìyá rẹ̀ pẹ̀lú Ọmọtádé tí wọ́n lọ pọn omi ní odò. Iyìọ̀lá àti Délọdún pinnu láti gbẹ̀san ìyà tí wọ́n fi jẹ wọ́n ní ọjọ́sí. Àwọn méjèèjì lọ so okùn pọ̀ ní ojú ọ̀nà wọ́n sì sá pamọ́ sínú igbó. Ẹ̀jìníkẹ̀ẹ́ àti Ọmọ́tọ́lá fi ẹsẹ̀ kọ́ okùn náà wọ́n sì da omi tí wọ́n rù nù, tí akèrègbè wọ́n sì fọ́. Inú bí ìyá Ẹ̀jìníkẹ̀ẹ́ ó sì bẹ̀rẹ̀ sí gbé àwọn ọmọ náà ṣépè.

Ní alẹ́ ọjọ́ kan àwọn ọmọdé péjọ nínú òṣùpá láti pa àlọ́. Àlọ́ àpamọ̀ ni wọ́n fi bẹ̀rẹ̀ lẹ́yìn náà wọ́n pa àlọ́ àpagbè. Wọ́n pa àlọ́ ajá àti ìjàpá. Wọ́n pa àlọ́ ẹkùn àti alábahun. Bákan náà ni wọ́n sọ ìtàn òkété tí ó lọ jí irú jẹ àti ìtàn ìyàwó méjì tí ọkọ wọn fi sílẹ̀ fún ọdún pípẹ́.

Lẹ́yìn èyí àwọn obìnrin ṣe eré sáńsálùbọ́ àwọn ọkùnrin sì ṣe eré olóbìíripo kí oníkálùkù tó gba ilé wọn lọ. Nígbà tí Délọdún dé ilé ó bá Katikîsì àti àwọn òbí rẹ̀ tí wọ́n ń sọ̀rọ̀ nípa ọkọ àfẹ́sọ́nà Àyọ̀ká. Wọ́n ti wá oúnjẹ alẹ́ tán. Délọdún lọ gbé oúnjẹ Katikîsì fún un, òu náà sì yára wá jẹ oúnjẹ alẹ́ rẹ̀.

**Orí Kejì: Mo Sùn Lóko**

Ìyá Délọdún rán an kí ó lọ sa ewé kòkó wá ní oko. Ibi tí ó ti ń sa ewé ni ó ti fi rọ́bà pa ọ̀hànràn. Ò gbé òhànràn náà fún ìyá rẹ̀. Lẹ́yìn tí ìyá rẹ̀ bá a wí ó ní òun yóò fi òhànràn náà ṣe àlejò Adéwálé ọ̀rẹ́ rẹ̀ ará Ìkérekú. Èyí mú kí Délọdún tún pinu láti wá kún ẹran tí wọn yóò fi ṣe àlejò láì sọ fún ẹnikẹ́ni.
Ó lọ sí oko ẹgàn láti lọ dẹ tàkúté fún àwọn àparò. Ó ní kí òun dúrò de alẹ́ pe bóyá ọwọ́ òun lè tẹ ọ̀kan nínú àwọn àparò náà. Ó fi ẹ̀yìn lélẹ̀ nínú ahéré kò sì mọ ìgbà tí oorun gbé e lọ. Ilẹ̀ ti ṣú kí ó tó tají. Ẹ̀rù bẹ̀rẹ̀ sí bà á. Ó gbìyànjú láti wá ojú ọ̀nà ó ń fi ìbẹ̀rù bojo lọ sí ọ̀nà ilé. Bí ó ti rìn díẹ̀ ó pàdé ọdẹ tí ó gbé iná lé orí. Ó yára sá sí ẹ̀yìn igi ńlá kan kí ọlọ́dẹ má baà rí i. bí ọlọ́dẹ ṣe kọjá tán ó tún tẹ̀ síwájú. Bí ó ti rìn díẹ̀ ó bẹ̀rẹ̀ sí gbọ́ ariwo àwọn tó ń wá a bọ.

Àwọn bàbá, ìyá àti gbogbo àwọn ènìyàn rẹ̀ ti dààmú púpọ̀ lórí rẹ̀. Wọ́n tilẹ̀ rò pé ó ti bọ́ sí ọwọ́ àwọn gbọ́mọgbọ́mọ. Wọ́n gbìyànjú wọ́n wá a lọ sí inú oko.  Bí wọ́n ṣe rí i bàbá rẹ̀ gbé e lé èjìká tí wọ́n sì gbé e wá sí ilé. Bí ó ṣe dé ilé ni ó jẹ àmàlà gbígbóná.

**Orí Kẹta: Ilé-Ẹ̀kọ́ Tún Bẹ̀rẹ̀**
Lẹ́yìn tí ìsinmi parí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tún padà sí ilé-ẹ̀kọ́ fún sáà titun. Ònkọ̀wé ṣàlàyé ipò tí àwùjọ to olùkọ́ sí ní àsìkò ìgbà náà. Àwọn òbí mú ọmọ wọn wá fún ìforúkọ sílẹ̀. Púpọ̀ nínú àwọn ọmọ wọ̀nyí ni olùkọ́ àgbà kọ̀ láti gbà. Olùkọ́ mẹ́rin ní ó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ ní àsìkò náà. Pàdé Àdìó ni olùkọ́ àgbà, Hábákúkù Odùṣọ̀tẹ̀ ni igbákejì, Ṣẹ́gun Adéníyì ni tísà kẹta. Lẹ́yìn tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbá gbogbo ilẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ tán wọ́n lọ sí odò láti fọ àga wọn. Wọ́n fọ àga tán wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ṣeré kiri. Ibi tí wọ́n ti ń ṣeré kiri ní bèbè odò ni Iyìọlá ti Fọláṣadé sínú ẹrọ̀fọ̀. Ọpẹ́lọpẹ́ àwọn alapákó ni wọ́n fi okùn fà á jáde nínú arọ̀fọ̀ náà.
Ṣadé àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ fi ẹjọ́ sun olùkọ́ àgbà, olùkọ́ àgbà pè wọ́n sí ọ́fíìsì rẹ̀. Bí Iyìọlá ṣe dé ilé-ẹ̀kọ́ ni ó ti sá lọ sí ilé. Olùkọ̀ àgbà yan àwọn géńdé mẹ́rin lọ gbé Iyìọlá wá. Lára wọn ni Sábíù, ọmọ ẹlẹ́ran àti Hẹsikáyà tí àpèjẹ́ rẹ̀ ń jẹ́ Àyà-bí-ẹ̀yìn. Olùkọ́ àgbà na Délọdún ní ẹgba mẹ́sàn-án ó na Iyìọlá ní ẹgba méjìlá.

Bàbá akọ̀pẹ náà wá láti kìlọ̀ fún àwọn olùkọ́ láti máa yan olùkọ́ tẹ̀lé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bí wọ́n bá rán wọn lọ sí ibìkan. Inú bí olùkọ́ àgbà èyí sì fẹ́rẹ̀ di ìjà láàrin wọn.

Kíláàsì kan náà ni Iyìọlá àti Délọdún wà. Ó jẹ́ kí á mọ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ ní kíláàsì wọn. Olùkọ́ a máa lo àpẹẹrẹ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kò mọ nǹkankan nípa rẹ̀. Bí wọ́n bá béèrè ìbéèrè lọ́wọ́ olùkọ́ ìjà ni yóò dà á sí bí kò bá mọ ìdáhùn sí ìbéèrè wọn.

Odùṣọ̀tẹ̀ ń kọ wọn ní ọjọ́ kan, Iyìọlá beèrè nípa aṣọ láńfúlẹ́. Gbogbo àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ̀rẹ̀ sí fi ọ̀gá wọn ṣe yẹ̀yẹ́. Inú bí Odùṣọ̀tẹ̀ ó sì lé gbogbo wọn jáde kí wọn lọ máa ro oko. Nígbà tí olùkọ́ àgbà gbọ́ ó pe Dékọdún àti ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀. Ó wádìí ohun tí ó ṣẹlẹ̀, ó sì bẹ Òdúsọ̀tẹ̀ kí ó má bínu. Lẹ́yìn náà ó pàṣẹ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa lọ sí kíláàsì wọn.

Púpọ̀ nínú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ni wọn kìí fẹ́ lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ nítorí ẹgba. Akẹ́kọ̀ọ́ mìíràn a ko páálí sí ìdí kí ẹgba má baà dùn wọ́n. Ní ọjọ́ kan Àyà-bí-èyìn fi ejò sí àpò wá sí orí ìlà. Bí Ọ̀gbéni Odùṣọ̀tẹ̀ ti ní kí òun nà án ní egba ni ejò jáde ní àpò rẹ̀ tí ó sì wé mọ́ Ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀ lọ́wọ́. Ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀ fi ariwo bọ ẹnu ó sì sá gba ilé rẹ̀ lọ.

Oríṣirísi ayé ni àwọn olùkọ́ ń jẹ lóko. Ìgbà mìíràn wọ́n lè ní kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ wá igi wá, wọ́n lè ní kí wọ́n wá ìgbín tàbí ìlákọ̀. Ìgbà mìíràn ó lè ṣe iṣu ni wọn yóò bèèrè lọ́wọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́. Iṣẹ́ ọwọ́ ní ìgbà náà sábà máa ń jẹ́ ìgbálẹ̀, apẹ̀rẹ̀, kùúkú tàbí àgò adìẹ ni wọ́n máa ń mú wá láti gba máàkì.

Ní ọjọ kan tí wọn lọ ṣiṣẹ nínú ọgbà ilé-ẹ̀kọ ni èdè-àì-yedè wáyé láàrin Ọ̀gbẹ́ni Oduṣọ̀tẹ̀ àti Ṣẹ́gun Adéníyì. Ìjà náà pọ̀ débi pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ̀rẹ̀ sí pariwo lé wọn lórí.

**Orí Kẹrin: Ojú Ń Rí Lóko**

Omi máa ń wọ́n púpọ̀ ní àsìkò ẹ̀rùn. Àwọn ènìyàn máa ń lọ sí odò láti gbẹ́ odò. Ní ọjọ́ kan tí wọ́n lọ gbẹ́ odò, àwọn obìnrin ṣèlérí láti pèsè oúnjẹ. Ibi tí wọ́n ti ń gbẹ́ odò wọ́n pa ọ̀pọ̀lọpọ̀ eku, àkèré àti kọ̀ǹkọ̀, wọ́n sì lọ kó o fún àwọn obìnrin kí wọ́n sè é mọ́ oúnjẹ. Bàbá kan wà níbẹ̀ ní ọjọ́ náà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ọ̀jẹ̀níyì, àwọn ènìyàn a má apè é ní bàbá Lááfíà. Nígbà tí ó rẹ bàbá yìí ó lọ fi ẹ̀yìn lélẹ̀ ní ibìkan. Kò mọ ìgbà tí ejò wọ inú ṣòkòtò rẹ̀. Ọgbọ́n ni wọ́n fi pa ejò náà tí kò fi pa baba lára. wọ́n sọ ohun tó ṣẹlẹ̀ fún bàbá. Ó mú àdá rẹ̀, ó gbọ̀nà ilé. Bí ó ṣe dé ilé ó ní kí wọ́n bá òun pa òbúkọ òun kí òun fi bọ orí. Wọ́n gé ejò náà sí mọ́kànlá wọ́n sì pín òbúkọ náà fún àwọn tó fẹ́ jẹ.

**Orí Karùm-ún: Kí La Lè Fi Wé**

Délọdún, Iyìọlá, Àkànmú àti Dọlápọ̀ ni wọ́n jọ ḿa ń ṣọ̀rẹ́. Délọdún àti Iyìọlá jọ ara wọn púpọ̀. Iyìọlá ní iṣẹ́ ọlọ́pàá tàbí iṣẹ́ ṣọ́jà ló wu òun. Délọdún ní iṣẹ́ dókítà ni òun fẹ́ ṣe. Dọlápọ̀ ní iṣẹ́ lọ́yà ni ti òun. Àkànmú ní iṣẹ́ woléwolé ló wu òun.
Bí ó bá di ti ìjà, Iyìọlá ni wọ́n máa ń tì í sí. Ní ti èébú Dọlápọ̀ ló mọ̀ nípa rẹ̀. Ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ́ iṣẹ́-ṣíṣe Àkànmú kò jáfara. Délọdún ní tirẹ̀ ló máa ń bá àwọn yòókù ṣe iṣẹ́ àṣetiléwá wọn. Iyìọlá le dé ibi pé ó bá gàǹbàrí jà ní ọjọ́ kan. Gàǹbàrí yọ ọ̀bẹ ó bẹ̀rẹ̀ sí lé wọn. Ojúẹsẹ̀ ni Iyìọlá náà yọ àdá sí gàǹbàrí ti gàǹbàrí sì sálọ. Bàbá Láfíà ní ẹnu, ó tún ní ahun àmọ́ ó máa ń sọ òtítọ́. Ní ọjọ́ Àbáméta kan àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin lọ wá igi tí wọn yóò fi dáná ìpàdé ẹgbẹ́ bàbá Dọlápọ̀. Bí wón ṣe wá igi tán ni wọ́n jókòó sí ọ̀dọ̀ bàbá Láfíà tí ó gbé iṣu tí ó fẹ́ jẹ ka iná. Bàbá yìí kò fẹ́ fún ẹnikẹ́ni jẹ èyí mú kí iṣu náà jóná sórí iná.

Bí òjò bá rọ̀ àwọn ọmọdé kìí rí àyè ṣeré ní ìta. Ṣùgbọ́n wọn a máa fi ẹnu dá ara wọn lárayá. Wọn a máa já àrọ̀, wọn a máa bú ìmọ̀ wọn a sì máa ka oríṣiríṣi àròfọ̀ ọmọdé. Ní ìgbà mìíràn wọn a máa ki ara wọn ní oríkì lóríṣríṣi láti mú inú ara wọn dùn.

Ìdí eré yìí ni wọ́n wà ní ọjọ́ kan ni ìyá rẹ̀ pè é kí ó wá lọ ata. Ó kọ́kọ́ kọ̀ sí ìyá rẹ̀ lẹnu àmọ́ nígbà tí bàbá rẹ̀ pariwo mọ́ ọn kíá ló lọ gbé ata náà tí ó sì lọ̀ ọ́. Àsìkò yìí ni wọ́n ń pàrọwà fún ẹ̀gbọ́n rẹ̀ Àyọ̀ká láti fẹ́ àfẹ́sọ́nà rẹ̀. Bàbá ní kí ìyá ní ṣùúrù kí ọkọ má tîi gbé ẹrù ìyàwó wá.

Kò pẹ́ sí àsìkò yìí tí ọkọ Àyọ̀ká bẹ géńdé méjọ ní abà Olórìṣà láti jí Àyọ̀ká gbé ní ọjọ́ tí òun àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ ń lọ sí ọjà Arúlógun. Òkìkí kàn dé abà Lábọ̀dé pé wọ́n ti jí Àyọ̀ká gbé lọ. Bàbá ní kí Fọlá pẹ̀lú géńdé mélòó kan lọ gba Àyọ̀ká sílẹ̀ lọ́wọ́ wọn. Bí àwọn onítọ̀hún ṣe dé ibẹ̀ wọ́n gba owó àti sìgá, wọ́n padà wálé lâì ṣe iṣẹ́ tí wọ́n rán wọn.

Inú bí Délọdún fún irú ìwà yìí ó sì yára gba ọ̀dọ̀ àbúrò ìyá rẹ̀ tó wà ní Ìkérekú. Dòkun sáré lọ mú ọlọ́pàá méjì ní Ìbàdàn tí wọ́n sì fi ìyà jẹ ọkọ Àyọ̀ká kí wọ́n tó tì í mọ́lé. Wọ́n gba Àyọ̀ká sílẹ̀ ó sì padà sí ilé wọn. Inú rẹ̀ dùn sí Délọdún nígbà tí ó gbọ́ pé òun ló lọ fi ọ̀rọ̀ náà tó Dòkun létí.

**Orí Kẹfà: Wọ́n Pè Mí Jẹ́rìí**

Ọkùnrin kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ládépò. Ojoojúmọ́ ni òun àti Àsùnlé, ìyàwó rẹ̀ jọ máa ń jà. Àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ gbà á ní ìmọ̀ràn láti fẹ́ ìyàwó mìíràn. Ládépò gba ìmọ̀ràn àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ ó sì lọ fẹ́ Àtọ́kẹ́. Àsìkò yìí ni ìjà wá

peléke si láàrin àwọn ìyàwó méjèèjì. Ẹlẹ́rẹ̀kẹ́ èébú ni Àtọ́kẹ́, ó lè bú ènìyàn láyin. Ní ọjọ́ kan, Àsùnlé bẹ Olú, ọ̀kan nínú àwọn ọmọ rẹ̀ láti bá òun fi èdè òyìnbó bú Àtọ́kẹ́. Olú kò gbọ́ òyìnbó tí ó lè fi bú ènìyàn ó sí bẹ̀rẹ̀ sí ka àkọ́sórí tí olùkọ́ kọ́ wọn ní ilé-ẹ̀kọ́. Inú túbọ̀ bí Àtọ́kẹ́, ó lérò oé èébú ni. Ó bẹ̀rẹ̀ sí gbé Olú ṣépè. Àwọn ènìyàn pé lé wọn lórí. Wọn bí Àtọ́kẹ́ bóyá ó mọ ìtumọ̀ òyìnbó tí Olú ń sọ. Ó ní òun kò gbọ́ òyìnbó. Wọ́n pe Délọdún kí ó wá túmọ̀ òyìnbó Olú. Nígbà tí wọ́n gbọ́ ìtumọ̀ òyìnbó Olú gbogbo wọn kú sílẹ̀ fún ẹ̀rín àríntàkìtì.

**Orí Keje: Eégún Ọdún**

Ní àsìkò ìsinmi àwọn Délọdún, Iyìọlá, Dọlápọ̀ àti Àkànmú tẹ̀lé bàbá wọn lọ sí ilé eégún ní ìlú Ìbàdàn. Ọdún eégún ku ọjọ́ mẹ́rin ni wọ́n kúrò lóko. Ẹsẹ̀ ni wọ́n fi rìn dé Òjé, ní àdúgbò wọn ní Ìbàdàn. Táyé àti Kẹ́hìndé wá kí wọn kú àbọ̀. Ìlú Ìbàdàn ni Táyé àti Kẹ́hìndé ń gbé ní tiwọn.
Ní ọjọ́ kejì Táyé àti Kẹ́hìndé mú wọn káàkiri ìgboro ìlú Ìbàdàn. Wọ́n lọ wo ọ̀ọ̀nì tí ó wà ní ilé Délé. Wọ́n lọ sí Òkè Ààrẹ láti lọ wo táwà Bower. Ní ìrọ̀lẹ́ ọjọ́ náà wọ́n lọ gbá bọ́ọ̀lù ní pápá ìṣèré Bower. Wọ́n padà sílé láti jẹun. Lẹ́yìn èyí wọ́n lọ sí ọjà alẹ́, wọ́n ra ìpápánu jẹ. Kò pẹ́ sí àsìkò yìí tí àwọn eégún fi ń jáde. Eégún tí wọ́n kọ́kọ́ rí ni Àyajinmọgìrì àti Atìpàkọ́ tíí ṣe olóri gbogbo eégún alágbo. Eégún yìí ló máa ń ṣúre fún gbogbo àwọn ìjòyè. ẹ̀rù rẹ̀ máa ń bà wọ́n, wọn kìí fẹ́ kí ó ṣúre fún àwọn. Òfin eégún ni pé eléégún méjì kò gbọdọ̀ pàdé ara wọn.  Bí wọ́n bá pàdé ọ̀kan gbọ́dọ̀ fi orí balẹ̀ fún ìkejì. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́ ìjà yóò ṣẹlẹ̀ láàrin wọn.

Ní ọjọ́ yìí eégún Afìdíẹlẹ́gẹ̀ẹ́-gbògiri pàdé eegún kan bayìí. Eégún kejì kọ̀ láti fi orí balẹ̀. Ìjà ṣẹlẹ̀ láàrin àwọn méjèèjì, eégún Afìdíẹlẹ́gẹ̀ẹ́ fi oyin ta eégún kejì àti àwọn elégbè rẹ̀. Lẹ́yìn èyí wọ́n pàdé Dúrónkíké kí wọ́n tó padà sílé. Ọjọ́ tí Alápáńsánpá jáde ni wọ́n tún rí ìran wò. Ògúndèjì ló ni eégún yìí eégún ọlọ́rẹ́ ni. Iwájú ilé ni wọ́n ti ń wò ó ní ọjọ́ náà. Àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ na bàbá àgbà kan ni ọjọ́ náà áwọn ọlọ́pàá ló wá gbé ọkùnrin náà lọ sí ilé ìwòsàn Adéọ̀yọ́. Bí ọdún eégún bá ń parí lọ ni Olóòlù máa ń jáde. Eégún yìí kò gbọdọ̀ fi ojú kan obìnrin. Ọjọ́ tí ó bá fi ojú kan obìnrin ni obìnrin náà yóò kú. Ìtàn tilẹ̀ sọ pé ọmọbìnrin rẹ̀ kan tí ó lọ pọn omi fi ojú kàn nígbà tí ó ń ti odò bọ̀. Ojúẹsẹ̀ ni ọmọ náà kú. Ṣùgbọ́n wọn kò rí àyè wo Olóòlù ní ọdún náà.

**Orí Kẹjọ: Àwa Náà Gbéégún**

Lẹ́yìn tí eégún ti kásẹ̀ nílẹ̀ ni ọpọ́n sún kan eégún ọmọdé tí wọ́n ń pè ní Tòǹbòlò. Táyé àti Kẹ́hìndé náà máa ń gbé eégún. Ọ̀dọ̀ ìyá àgbà ni wọ́n máa ń fi ẹ̀kú wọn sí. Ẹ̀kú náà ti fàya, ṣùgbọ́n wọ́n wá ọ̀nà láti rán an. Kéhìndé mú ìborùn ìyá rẹ̀, Iyìọlá lọ jí fìlà bàbá rẹ̀ mú. Dọlápọ̀ mú ìbọ̀sẹ̀ pupa ẹ̀gbọ́n rẹ̀ tíṣà. Délọdún jí abẹ́rẹ́ méjì àti òwú dúdú kan lọ́dọ̀ bàbá Gàní tó ń rán aṣọ lójúde.
Táyé ló gbé eégún Kẹ́hìndé ṣe atọ́kùn àwón yòókù mú ẹgba dání. Kò pẹ́ tí wọ́n fi di elérò lẹ́yìn. Àwọn ọmọdé bẹ̀rẹ̀ sí fi eégún náà ṣe yẹ̀tẹ́. Bí wọ́n ti ń fi í ṣe yẹ̀yẹ́ ni ó ń kó ẹgba bò wọ́n. Bí wọ́n ṣe ń lọ ni wọ́n ń gba tọ́rọ́ kọ́bọ̀ lọ́wọ́ àwọn ènìyàn. Àṣírí eégún náà fẹ́rẹ̀ tú nígbà tí wọ́n jó dé ọ̀dọ ẹ̀gbọ́n Dọlápọ̀.

Lẹ́yìn èyí wọ́n gbé eégún lọ sí ilé wọn. Bí ìyá ìbejì ti rí wọn ni ó rí i pé ìborùn òun ni wọ́n lẹ̀ mọ́ ara ẹ̀kú eégún. Ó tàka sí eégún náà pé nígbà tí ó bá dé ilé ní alẹ́. Wọ́n kúrò níbẹ̀ lọ sí ọ̀nà ọjà. Níbẹ̀ ni wọ́n ti pàdé Tòǹbòlò mìíràn. Iyìọlá fẹ́ dá ìjà sílẹ̀ láàrin eégún náà. Ṣùgbọ́n Kẹ́hìndé ló bá wọn parí rẹ̀. Bí Táyé ti rí eégún náà ló forí balẹ̀ tí ó sì bá tirẹ̀ lọ torí ó mọ̀ pé eégún náà dàgbà ju òun lọ. Bí wọ́n ṣe dé ilé ní ọ̀ọ́ yìí ni ìyá ìbejì àti bàbá Iyìọlá bẹ̀rẹ̀ sí bá wọn wí fún ìborùn àti fìlà ti wọ́n jí mú. Ọpẹ́lọpẹ́ ìyá àgbà ni ó gbà wọ́n sílẹ̀ tí kò jẹ́ kí wọ́n jẹ ẹgba ní ọjọ́ náà.

**Orí Kẹsàn-án: Gbogbonìṣe**

Okùnrín kan wà tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Àìsáyà ṣùgbọ́n Àrìsáyà Onígbogbonìṣe ló ní kí wọ́n máa pe òun. Kò sí ẹni tí o mọ ibi tí bàbá náà ti máa ń wá. Òògùn òyìnbó ló máa ń tà. Bàbá yìí á dúró sí iwájú ìta á máa polówó òògùn rẹ̀. Ó lè wí pé òògùn ẹyọ kan lè wo igba ààrùn. Ara bàbá ọdẹ kò yá ní ọjọ́ kan. Ọmọ rẹ̀, Ògúngbárò, gbó nípa òògùn apa-kòkòrò tí bàbá ń polówó ó sáré lọ rà á fún bàbá rẹ̀. Dípò kí bàbá lò ó bí ó ṣe yẹ kí ó lò ó, bàbá ṣi òògùn kò. Èyí ló sì fa ikú rẹ. Òkìkí kàn dé gbogbo abúlé. Láti ọjọ́ náà ni wọn kò ti rí bàbá náà mọ́.

**Orí Kẹwàá: Olúṣọlá**

Ọmọ kan wà tí ó ń jẹ́ Olúṣọlá. Olúṣọlá kò lè jà ṣùgbọ́n ó ní ẹnu. Bí ó bá fẹ́ bá ènìyàn jà á bọ́ aṣọ fún àbúrò rẹ̀, Olúrántí, pé kí ó lọ fún ìyá òun. Bí ìyá bá ti rí aṣọ ọmọ rẹ̀ ni yóò ti máa sáré bọ̀ pé ọmọ òun ti ń jà. Bí Olúṣọlá bá ti rí ìyá rẹ̀ ni yóò múra sí ẹnu dídán.

Ní ọjọ́ kan ní ilé-ẹ̀kọ́, ìjà ṣẹlẹ̀ láàrin òun àti Iyìọlá. Kí ó tó sọ pé òun bọ́ aṣọ fún àbúrò rẹ̀ Iyìọlá ti gbá a ní etí méjì, ó kó o ní ẹsẹ̀, ó fi ẹ̀yìn rẹ̀ balẹ̀ ó sì ń lù ú bí i bàrà. Ọpẹ́lọpẹ́ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ tí ó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ ló gbà á sílẹ̀ ní ọjọ́ náà.

**Orí Kọkànlá: Olùbẹ̀wò**

Kò pẹ́ tí wọ́n wọlé lẹ́yìn ìsinmi ọ̀gá-àgbà sọ fún wọn pé olùbẹ̀wò ǹ bọ̀ wá sí ilé-ẹ̀kọ́. Bí àwọn olùbẹ̀wò bá fẹ́ wá tẹ́lẹ̀ wọn kìí sọ fún ẹnikẹ́ni. Ó rántí ọjọ́ kan tí olùbẹ̀wò gba ojú fèrèsé wọlé. Bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe rí i ó fi ọwọ́ sọ fún wọn kí wọ́n má sọ̀rọ̀. Òjijì ló bá Ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀. Iṣẹ́ tó ń kọ́ wọn ní ọjọ́ náà sálọ ní agbárí rẹ̀. Inú bí olùbẹ̀wò ó sì mú Ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀ lọ sí ọ̀dọ̀ ọ̀gá àgbà.

Ní ti ọ̀tẹ̀ yìí olùbẹ̀wò ti ránṣẹ́ síwájú. Bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe ń múra ni àwọn olùkọ́ náà ń múra. Ọ̀gá àgbà ṣe ìfilọ̀ ní ilé ìjọsin àwọn ìjọ pinnu láti fún olùbẹ̀wò ní adìrẹ méjì àti ẹyin méjìlá pẹ̀lú ságo ẹmu mẹ́fà. Lẹ́yìn àbẹ̀wò, ó gbé oríyìn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn olùkọ́ pé ilé-ẹ̀kọ́ wọn ló ṣe dáradára jù nínú gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ tí olùbẹ̀wò dé ní ọ̀sẹ̀ náà̀.

**Orí Kejìlá: Kòríkòsùn**

Àwọn méjọ ni Délọdún jọ máa ń rìn papọ̀. Nínú àwọn méjọ yìí, yàtọ̀ sí Délọdún àti Àkànmú, òun àti Iyìọlá ni wọ́n fẹ́ràn ara wọn jù. Ọ̀rẹ́ kòríkòsùn ni wọ́n. Bí ìgbín fà ìkarahun a tẹ̀lé e. bí wọ́n ń lọ sóko tàbí odò wọn á jọ lọ ni. Wọ́n tú jọ ara wọn púpọ̀. Wọ́n ga bákan náà. Wọ́n dúdú bákan náà, wọ́n sì sanra bákan náà.

Alẹ́ ọjọ́ kan wà tí àwọn méjèèjì ń gún èlùbọ́ ní iwájú ìta. Iyìọlá ṣẹ̀ ìyá rẹ̀ ní ọjọ́ yìí ìyá rẹ̀ sì fẹ́ bá a wí. Dípò kí ìyá na Iyìọlá, Délọdún ni ó kó egba bò tí ó lérò pé ọmọ òun ni.

**Orí Kẹtàlá: Agbóyìnbó Kì í Kú Sílé.**

Ìfẹ́ Délọdún àti Iyìọlá ni pé kí wọ́n jọ gbé pẹ́ títí. Àmọ́ ìfẹ́ àwọn òbí wọn kò jẹ́ kí èyí ṣe é ṣe. Ohun tí ó wù wọ́n ni pé kí àwọn méjèèjì máa lọ gbé ní Ìbàdán lọ́dọ̀ ìyá àgbà láti tẹ́síwájú nínú ẹ̀kọ́ wọn.

Ìbànújẹ́ ni ó jẹ́ fún wọn láti gbọ́ pé Délọdún níkan ni yóò lọ máa gbé ní ọdọ̀ ìyá àgbà. Iyìọlá yóò má ti Lábọ̀dé lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ tó wà ní Ìkérekú. Dọlápọ̀ yóò ló máa gbé ní ọ̀dọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀ kan tí ó ń ṣe iṣẹ́ olùkọ́ ní ọ̀ná Ifẹ̀. Àkànmú nítirẹ̀ yóò lọ máa gbé ọ̀dọ̀ ẹ̀gbọ́n wọn kan tí ó jẹ́ ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ ní Òkìtìpupa.

Ní ọjọ tí Àkànmú lọ gbogbo ará abúlé ló sìn wọ́n sí ojú ọ̀nà. Àwọn ọmọdé ẹgbẹ́ rẹ̀ sìn ín dé Ìkérekú kí wọ́n tó padá.

Nígbà tí ó ku ọ̀la tí Délọdún má lọ sí Ìbàdàn òun àti Iyìọlá pẹ̀lú Dọlápọ̀ jọ ń jíròrò ní iwájú ìta ní alẹ́ ọjọ́ náà. Wọ́n sọ̀rọ̀ títí ilẹ̀ fi ṣú. Ìyá rẹ̀ ló pè wọ́n wọlé pé kí wọ́n tètè lọ sùn nítori ìrìn àjò re. bàbá rẹ̀ gbà á ní ìmọ̀ràn kí ó tó lọ sí oko. Ìfẹ́ àarin òun àti Àyọ̀ká pọ̀ sí i láti ìgbà tí wọ́n ti gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ ọkọ àfẹ́sọ́nà rẹ̀. Bí ó ti kù díẹ̀ kí wọ́n gbéra ni ìyá rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí kì í ní oríkì. Bí ìyá rẹ̀ ṣe ń kì í ni orí rẹ̀ ń wú tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí sunkún.
Ó gbé ẹrú rẹ̀ ó gbọ̀nà ìkérekú. Ìyá rẹ̀, Àyọ̀ká àti àwọn ọ̀rẹ́ ló bá a dé Ìkérekú. Ọkọ̀ akérò tí wọ́n kọ "Tọbalàṣẹ" sí lára ló wọ̀ dé Ìbàdàn.

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Ta ni olú ẹ̀dá ìtàn ìwé Ogún Ọmọdé?
2. Dárúkọ àwọn ẹ̀dá ìtàn márùn-ún mìíràn nínú ìwé náà.
3. Tọ́ka sí àṣà Yorùbá méjì tí ó jẹyọ nínú ìwé yìí.
4. Ṣàlàyé ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ fọ àga ní odò.
5. Kí ni ohun tí ó ṣẹlẹ̀ láàrin ọ̀gbẹ́ni Ṣẹ́gun àti Ọ̀gbẹ́ni Odùsọ̀tẹ̀?

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Dárúkọ oríṣi eégún mẹ́rin tí òǹkọ̀wé mẹ́nubà nínú ìwé yìí.
2. Ménuba eré ìdárayá mẹ́ta pàtàkì tí ó jẹyọ nínú ìwé yìí.

## Week 3: Ọ̀sẹ̀ Kẹta

## Àṣà Ìsìnkú Nílẹ̀ Yorùbá.

Àṣà ìsìnkú jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà ṣe ìpalẹ̀mọ́ fún ẹni tí ó kú. Oríṣi òkú ló wà. Òkú àgbà (òkú ẹ̀kọ) àti ọ̀kú ọ̀fọ̀. Òkù ọ̀fọ̀ ni òkú ọmọdé, ọ̀dọ́ tàbí àgùnbánirọ̀.

**Ìtúfọ̀**

Àwọn Yorùbá kì í túfọ̀ ọmọdé, ọ̀dọ́ tàbí àgùbánirọ̀. Igbe ẹkún ni wọ́n fi ń tú ọ̀fọ̀ irú òkú bẹ́ẹ̀. Bí ó bá ṣe òkú àgbàlagbà ni oríṣi ọ̀nà ni wọ́n ń gbà tú ọ̀fọ̀ wọn.
Ní ayé àtijọ́ wọn a máa fi ìbọn tú ọ̀fọ̀ àgbàlagbà. nígbà mìíràn ó lè jẹ́ ijó, ìlù àti orin ni wọn yóò fi tú ọ̀fọ̀. Ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ ìlu gbẹ̀du ni wọ́n fi ń túfọ̀ ọba ìlú. Ó máa ń tó oṣù mẹ́ta kí wọ́n tó túfọ̀ ọba. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹrú àti ẹrù ni wọ́n máa ń sin pẹ̀lú ọba láyé àtijọ́.

**Adìẹ Ìrànà**

Ẹ̀yí ni adìẹ tí a fi ń ra ọ̀nà fún òkú tí a ń gbé láti oko bọ̀ wá sí ilé. Àkọ́bí òkú ni yóò mú adìẹ ààyè lọ́wọ́ níwájú. Yóò máa tu ìyẹ́ rẹ̀ ní àturìn. Àwọn tó gbé ọ̀kú yóò tẹ̀lé e lẹ́yìn tí ẹnìkan yóò sì máa ta epo pupa sílẹ̀ ní àtarìn bọ̀ lẹ́yìn wọn. Báyìí ni wọn yóò ṣe títí wọn yóò fi dé ilé. Bí wọ́n bá ti dé ilé ni wọn yóò pa adìẹ yìí tí wọn yóò sì fi pèsè oúnjẹ fún àwọn tó gbé òkú wálé.

**Ìlẹ̀pa Òkú**

Ìlẹ̀pa òkú ni erùpẹ̀ tí a bù nínú sààréè òkú. Àkọ́bí òkú ló máa ń la ilẹ̀ ókú. Bí wọ́n bá ti wọn ilẹ̀ tán wọn yóò fi ọkọ́ kó èèpẹ̀ ibẹ̀ jọ sí apákan. Bí wọ́n bá gbẹ́ ilẹ̀ òkú tán wọn yóò tún fi ọkọ́ ha ìsàlẹ̀ pátápátá. Wọn yóò da méjèèjì pọ̀. Irú erùpẹ̀ báyìí ni wọn ń pè ní ìlẹ̀pa òkú.

**Ìtọ́jú Òkú**

1. Wíwẹ̀ fún òkú
2. Fífá irun orí òkú tí ó jẹ́ ọkùnrin.
3. Kíkó tàbí dídi irun fún òkú obìnrin.

4. Gígé èékánná òkú.
5. Ṣíṣe òkú lóge.
6. Títẹ́ òkú ní ìtẹ́ ẹ̀yẹ.
7. Gbígbé eégún òkú.
8. Sísin òkù pẹ̀lú ìnáwó rẹpẹtẹ.

**Bí a ti ń sin òkú abàmì ẹ̀dá.**

| Òkú Abàmì Ẹ̀dá | Bí a ti ń sin wọ́n |
|---|---|
| 1. Òkú Ṣàngó | Àwọn mọgbà ló ń ṣe ètùtù sísin wọn. |
| 2. Òkú sànpọ̀nná | Àwọn adáhunṣe ló máa ń sin wọ́n sínú igbó. |
| 3. Òkú omi | Àwọn olórò ló máa ń sin wọ́n sí etí odò lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù. |
| 4. Òkú aláboyún | Àwọn olórò ló máa ń sin wọ́n lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù. |
| 5. Òkú adẹ́tẹ̀ | Àwọn adáhunṣe ló máa ń ṣe ètùtù òkú wọn. Inú igbó ni a máa ń sin adẹ́tẹ̀ sí. |
| 6. Ẹni tó pokùnso. | Àwọn olórò ló máa ń sin òkú wọn lẹ́yìn ètùtù. |
| 7. Òkú abuké | Àwọn adáhunṣe ló máa ń ṣe ètùtu sísin òkú wọn. Inú ìkòkò ni wọ́n máa ń sin abuké sí. |
| 8. Ẹni tó jábọ́ lóri igi tí ó sì kú. | Ìdí igi náà ni àwọn olórò máa sin òkú bẹ́ẹ̀ sí lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù. |
| 9. Òkú ọdẹ | Àwọn ọdẹ ló máa ń ṣe ètùtù ikú wọn. Ìrèmọ̀jé ni orò tí wọ́n máa ń ṣe fún ọdẹ tí ó bá kú. |

**Ìrèmọ̀jé eré ìṣípà ọdẹ**

Ìrèmọ̀jé ni orò ìkẹ́yìn tí wọ́n máa ń ṣe fún ọdẹ tí ó bá kú. Ìrèmọ̀jé ni a fi ń yọ ọwọ́ kílàńkó ọdẹ tí ó kú kúrò nínú ẹgbẹ́ ọdẹ. Ẹ̀yí máa ń wáyé nípa ìpà kíkó.

Wọn yóò kó gbogbo ohun èlò tí ọdẹ yìí ń ló nígbà ayé rẹ̀ lọ sínú igbó tàbí lẹ́yìn odi ìlú. Wọn yóò gbẹ́ ère rẹ̀ wọn yóò wọ̀ gbérí ọdẹ fún ère náà, wọn yóò sì kó gbogbo ohun èlò ọdẹ náà síwájú rẹ̀ ní ọ̀kọ̀ọ̀kan. Ìrèmọ̀jé ni orin ọdẹ tí wọn yóò máa kọ.

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Dárúkọ ọ̀nà márùn-ún tí a ń gbà tọ́jú òkú láyé àtijọ́.
2. Kí ni àwọn Yorùbá ń pè ní ìlẹ̀pa òkú?
3. Ṣàlàyé ohun tí o mọ̀ nípa ìrèmọ̀jé.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Báwo ni àwọn Yorùbá ṣe ń sin òkú wọ̀nyí láyé àtijọ́?
   a. Òkú aláboyún
   b. Òkú adẹ́tẹ̀
   c. Òkú abuké
   d. Òkú ẹni tó pokùnso.
   e. Òkú ẹni tó kú sínú omi.

**Ọ̀sẹ̀ Kẹrin**

**Gbólóhùn Èdè Yorùbá**

Gbólóhùn ni ẹyọ tàbí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tí ó ní ìtumọ̀ kíkún tí ó sì tẹ̀lé ìhun gírámà èdè Yorùbá. Gbólóhùn gbọ́dọ̀ ní ọ̀rọ̀-ìṣe, ó gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú lẹ́tà ńlá ó sì gbọdọ̀ parí pẹ̀lú àmì ìdánudúró, àmì ìbéèrè tàbí àmì ìyanu.

**Ìsọ̀rí Gbólóhùn Èdè Yorùbá.**

A lè pín gbólóhùn sí ọ̀nà méjì.

1. Ìsọ̀rí gbólóhùn nípa ìhun.
2. Ìsọ̀rí gbólóhùn nípa iṣẹ́.

**Ìsọ̀rí Gbólóhùn nípa ìhun.**

A lè pín gbólóhùn sí ọ̀nà mẹ́ta nípa ìhun:

1. Gbólóhùn abọ́dé (Ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe)
2. Gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe.
3. Gbólóhùn alákànpọ̀.
4. Gbólóhùn oníbọ̀.

1. Gbólóhùn Abọ́dé / Ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe: Èyí ni gbólóhùn tí ó ní ẹyọ ọ̀rọ̀-ìṣe kan nínú ìhun rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Àlàbá ra mọ́tò.
   b. Fúnmiláyọ̀ sùn.
   c. Bàbá ọdẹ pa ẹran ọ̀yà ní oko ẹgàn.

2. Gbólóhùn Ọlọ́pọ̀ Ọ̀rọ̀-Ìṣe: Èyí ni gbólóhùn tí ó ní ọ̀rọ̀-ìṣe méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ:

| | |
|---|---|
| a. Mo ra ẹ̀pà jẹ. | Mo ra ẹ̀pà |
| | Mo jẹ ẹ̀pà |
| b. Ìyàwó gbé ọmọ pọ̀n. | Ìyàwó gbé ọmọ. |
| | Ìyàwó pọn ọmọ. |
| c. Bọ́lá lọ ra iṣu tà ní ọjà. | Bọ́lá lọ. |
| | Bọ́lá ra iṣu ní ọjà. |
| | Bọ́lá ta iṣu ní ọjà. |

3. Gbólóhùn Alákànpọ̀: Èyí ni gbólóhùn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí a fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ sọ di ẹyọ kan. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Mo lọ sí ilé Adé àmọ́ n kò bá a nílé.
   b. Kọ́lá wá ṣùgbọ́n ó pẹ́ dé.
   c. Tọ́pẹ́ jẹ ìrẹsì ó sì mu omi.

### 4. GBÓLÓHÙN ONÍBỌ̀

Eyi ni gbolohun ti o ni olori awe gbolohun ati awe gbolohun afarahe

***a. Olori awe gbolohun – Main clause(independent clause)***

Eyi ni gbolohun ti o le da duro pelu itumo kikun. Bi apeere:

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn Afarahẹ |
|---|---|---|---|
| 1. | Bọ̀dé kọ́ ilé tí ó tóbi. | Bọ̀dé kọ́ ilé. | Tí ó tóbi. |
| 2. | Àjàlá ra dòdò àti ìrẹsì tí ó fẹ́ jẹ. | Àjàlá ra dòdò àti ìrẹsì. | Tí ó fé jé. |
| 3. | Ó dára kí akẹ́kọ̀ọ́ múra sí ẹ̀kọ́ rẹ̀. | Ó dára. | Kí akẹ́kọ̀ọ́ múra sí ẹ̀kọ́ rẹ̀. |
| 4. | Kò yẹ kí á máa oògùn olóró | Kò yẹ. | Kí a mu oògùn olóró. |
| 5. | Mo mọ̀ pé ọ̀gá fẹ́ràn mi. | Mo mọ̀. | Pé ọ̀gá fẹ́ràn mi. |

**IṢẸ́ ṢIṢẸ – EXERCISE 6.1**

**Pín gbólóhùn  ìsàlẹ̀ yìí sí olórí awẹ́ gbólóhùn àti awẹ́ gbólóhùn afarahẹ.**

Answer:

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn Afarahe |
|---|---|---|---|
| 1. | Ìdòwú wá igi tí ó fẹ́ fi dá iná. | | |
| 2. | Ìyábọ̀ ra bàtà tí ó fé wọ̀. | | |
| 3. | Ó yẹ kí ọmọ gbọ́ràn sí òbí rẹ̀ lẹ́nu. | | |
| 4. | Àjàyí jẹun kí ó tó lọ sí ọjà. | | |
| 5. | Ọ̀yà tí bàbá ọdẹ pa tóbi púpọ̀. | | |

***a. Awé gbólóhùn afarahẹ- Subordinate clause (dependent clause)***

Èyí ni gbólóhùn tí kò lè dá dúró pẹ̀lú ìtumọ̀ kíkún àyàfi tí ó bá fi ara hẹ olórí awẹ́ gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn afarahẹ |
|---|---|---|---|
| 1. | Bí mo bá rí ìwé ìpè màá wá sí ìpàdé náà. | Màá wá sí ìpàdé náà. | Bi mo ba ri iwe ipe |
| 2. | Ọkọ̀ tí Bọ̀dé rà dára púpọ̀. | Ọkọ̀ dára púpọ̀. | Tí Bọ̀dé rà |
| 3. | Kí ìdánwò tó dé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé wọn. | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ka ìwé wọn. | Kí ìdánwò tó dé. |
| 4. | Aṣọ tí Àìná wọ̀ dọ̀tí. | Aṣọ dọ̀tí. | Tí Àìná wọ̀. |
| 5. | Wọ́n ń pariwo bí ó ṣe wù wọ́n. | Wọ́n ń pariwo. | Bí ó ti wù wọ́n. |

**IṢẸ́ ÀṢETILÉWÁ – ASSIGNMENT 6.0**

Parí àtẹ ìsàlẹ̀ yìí pẹ̀lú gbólóhùn tí ó yẹ

| | Gbólóhùn Oníbọ̀ | Olórí Awẹ́ Gbólóhùn | Awẹ́ Gbólóhùn afarahẹ |
|---|---|---|---|
| 1. | | Àlàbá ra ọkọ̀ | Kí ó took ilé |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 2. | Ajá tí ó tóbi pọ̀ ní Oǹdó. | | Tí ó tóbi. |
| 3. | Wọ́n ń ṣiṣẹ́ kí wọ́n lè lówó lọ́wọ́. | Wọ́n ń ṣiṣẹ́ | |
| 4. | | Mo gbọ́. | pé o bímọ titun. |
| 5. | Kò yẹ kí á má abá ara wa ja | | |

**Ìsọ̀rí Gbólóhùn Nípa Iṣẹ́**

1. Gbólóhùn Ìbéèrè: Èyí ni gbólóhùn tí a fi ń bèèrè ọ̀rọ̀ lọ́wọ́ ẹni. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Níbo ni Àjàyí lọ?
   b. Ta ni ló ń sọ̀rọ̀?
   c. Ìgbà won i Àkànjí ti ọjà dé?
5. Gbólóhùn Àṣẹ: Èyí ni gbólóhùn tí a fi ń pàṣẹ fún ènìyàn láti ṣe ohun tí a fẹ́. bí àpẹẹrẹ:
   a. Dìde
   b. Dákẹ́ ariwo.
   c. Padà wá.
   d. Bá mi bu omi wá.
6. Gbólóhùn alálàyé: Èyí ni gbólóhùn tí a fi ń ṣàlàyé bí nǹkan ṣe rí fún ẹlòmíràn. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Òjò náà férẹ̀ wú òkú ọ̀lẹ.
   b. Ọwọ́ àwọn ọlọ́pàá tẹ ọmọ tó jalè.
   c. Ilé wọn ga gogoro.
7. Gbólóhùn Oníròyìn: Èyí ni gbólóhùn tí a fi ń ṣe ìròyìn tàbí àgbàrán fún ẹlòmíràm. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Àkànjí sọ pé oúnjẹ òun keéré.
   b. Bánjí ni òun yóò wá ní ìrọ̀lẹ́.
   c. Wọ́n ní ebi ń pa àwọn.
8. Gbólóhùn Ìyísódì: Èyí ni gbólóhùn tí a fi ń yí ohun tí a sọ padà sí òdì. Bí àpẹẹrẹ:
   a. Ìdòwú kò jẹ ẹja gbígbẹ rí.
   b. Àjàlá kì í jẹ ajá.
   c. Má pariwo mọ́.
9. Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumo: Èyí ni gbólóhùn ti a fi ń ṣe ìtẹnumọ́ láti pe àkíyèsí ẹni sí nǹkan tí a ń sọ nípa rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:
   Mo ra ilẹ̀ ní Àbújá.
   Mo – Èmi ni mo ra ilẹ̀ ní Àbújá.
   Rà – Rírà ni mo ra ilẹ̀ ní Àbújá.
   Àbújá – Àbújá ni 14mo ti ra ilẹ̀.

   **Iṣẹ́ Kíláàsì**
   1. Kí ni gbólóhùn?
   2. Kọ àpẹẹrẹ gbólóhùn márùn-ún sílẹ̀.
   3. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ kọ̀ọ̀kan, dárúkọ orísi gbólóhùn mẹ́ta nípa ìhun.

   **Iṣẹ́ Àṣetiléwá**
   1. Yẹ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn gbólóhùn wọ̀nyí wò kí o sì sọ irú gbólóhùn tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n jẹ́.

a. Àlàbá ra aṣọ titun,
b. Wọ́n jẹun àmọ́ wọn kò yó.
c. Kọ́láwọlé ni ó ń pariwo.
d. Fúnmiláyọ̀ ń pọn omi tà.
e. Àlàbá kò lọ sí ilé-èkọ́ ní àná.

**Ọ̀sẹ̀ Karùn-ún – Week 5**

**Eré Ìdárayá Nílẹ̀ Yorùbá.**

Èyí ni eré tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe nígbà tí ọwọ́ bá dilẹ̀, ní ìrọ̀lẹ́, lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Orísirísi eré ìdárayá ló wà. Eré ọkùnrin wà ti obìnrin sì wà pẹ̀lú. Eré ọmọdé wà ti àwọn àgbàlagbà sì wà. Nínú òṣùpá ni àwọn ọmọdé máa ń ṣe eré tiwọn. Ìdí nìyí tí a fi ń pè é ní eré òṣùpá. Àpẹẹrẹ ni bojú-bojú, ẹkùn mẹ́ẹ̀ran, ta ló wà nínú ọgbà náà, kí ní ń lẹ́jẹ̀, bọ́ọ́kọ-bọ́ọ̀kọ. Eré ìta gbangba nit i àwọn nit i àwọn ọ̀dọ́. Àpẹẹrẹ ni ẹkẹ tàbí ìjàkadì, òkòtó, eré àrín, kannakánná àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn obìnrin ló ń ṣe bọ́ọ́kọ-bọ́ọ̀kọ àti ta ló wà nínú ọgbà náà? Tọkùnrin tobìnrin ló ń pa àlọ́. Tọba tìjòyè ló ń ta ayò lábẹ́lé tàbí níta gbangba.

Gbogbo àwọn eré wọ̀yí ló wà fún ìdárayá. Wọ́n máa ń mú orin, ẹ̀fẹ̀ àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwàdà dání. Àwọn eré wọ̀nyí kò wà fún ọlọ́kùnrùn tàbí aláìsàn.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ eré abínibí ilẹ̀ wa wa ni a ti pati, eré ìdárayá ti òyìnbó ni a fi dípò. Eré ayò àti 'draft' ti àwọn òyìnbó fẹ́rẹ̀ báramu. Bákan náà ni ìyàtọ̀ díẹ̀ ló wà nínú ẹkẹ àti ìjàkadì pẹ̀lú wresling.

**Oríṣi Eré Ìdárayá**

Ọ̀nà mẹ́rin pàtàkì ni a lè pín eré ìdárayá sí.

a. Eré òṣùpá
b. Eré ojúmọmọ.
c. Eré abẹ́lé.
d. Eré ìta gbangba.

1. Eré Òṣùpá:Èyí ni eré tí wọ́n máa ń ṣe ní alẹ́, ní àsìkò tí òṣùpá bá ràn. Àpẹẹrẹ ni àlọ́ àpamọ̀ àti àlọ́ àpagbè, bojú-bojú, ẹkùn mẹ́ẹ̀ran, ta ló wà nínú ọgbà náà, sáǹsálùbọ́, ẹ bá mi gbọ́ndò yìí gbẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
2. Eré ojúmọmọ: Èyí ni eré tí wọ́n máa ń ṣe ní ìrọ̀lẹ́, nígbà tí ilẹ̀ kò tí ì ṣú. Àpẹẹrẹ ni eré ayò, eré òkòtó, òǹgo gbígbọ̀n, eré àrín abbl.
3. Eré abẹ́lé: èyí ni eré ti wọ́n máa ń ṣe ní abẹ́ òrùlé. Bí àpẹẹrẹ: eré ayò, bọ́ọ́kọ-bọ́ọ̀kọ, kí ní ń lẹ́jẹ̀, ẹyẹ mẹ́ta tolongo wáyé, eré òkòtó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
4. Eré ìta-gbangba: Èyí ni eré tí wọ́n máa ń ṣe ni gbangba ìta. Àpẹẹrẹ ni ẹkẹ tàbí ìjàkadì, eré àrín, ẹkùn mẹ́ẹ̀ran, ta ló wà nínú ọgbà náà, ẹ bá mi gbọ́ndò yìí gbẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àǹfààní Eré Ìdárayá.

1. Ó máa ń jẹ́ kí ènìyàn tètè ronú.
2. Ó máa ń jẹ́ kí á gbọ́ èdè dáradára.
3. Ó máa ń mú ara ẹni yá gágá.
4. Ó máa ń dènà àrùn lára ẹni.
5. Ó ń jẹ́ kí ìfẹ́ àti ìrẹ́pọ̀ wà láwùjọ.

**Àléébù Eré Ìdárayá.**

1. Ó máa ń jẹ́ kí ènìyàn fi ara pa.
2. Ó máa ń sọni di ọ̀lẹ.

3. Ayò àtajù kìí jẹ́ ki ènìyàn rí ààyè látí gbọ́ ti ìdílé rẹ̀.
4. Eré ìdárayá a máa dá ìjà sílẹ̀ ní ìgbà mìíràn.

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Ọ̀nà mélòó ni a lè pín eré ìdárayá sí? Dárúkọ wọn.
2. Ṣàlàyé mẹ́ta nínú eré ọmọdé tí o mọ̀.

**Ìṣẹ́ Àṣetiléwá.**

1. Ṣàlàyé ohun tí o mọ̀ nípa eré ayò.
2. Dárúkọ eré ìdárayá ìgbàlódé márùn-ún tí o mọ̀.

## Ọ̀sẹ̀ Kẹfà – Week 6
## Ìtẹ̀síwájú Ìwé Ìtàn Àpilẹ̀kọ
## Àwọn Ẹ̀dá Ìtàn

1. Délọdún
2. Àwọn ọ̀rẹ́ Délọdún; Iyìọlá, Dọlápọ̀ àti Àkànmú.
3. Ìyá àti bàbá rẹ, Àyọ̀ká àti Bọ̀dé àwọn ẹ̀gbọ́n Délọdún.
4. Bàbá Dọlápọ̀ àti ìyàwó baálé.
5. Fọlá, Ejiníkẹ̀ẹ́ àti ìyá rẹ̀.
6. Àwọn olùkọ́; ọ̀gá àgbà, Ọ̀gbẹ́ni Odùṣọ̀tẹ̀, Ṣẹ́gun Adéníyì àti olùkọ́ kékeré.
7. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́; Fọláṣadé, Sábíù, ọmọ ẹlẹ́ran, Hẹsikáyà Adéníyì tí ìnagigẹ rẹ̀ ń jẹ́ Àyà-bí-ẹ̀yìn.
8. Àwọn ará abúlé: Ọ̀jẹ̀níyì tí wọn ń pè ní bàbá Láfíà,
9. Àfẹ́sọ́nà Àyọ̀ká, Dòkun – àbúrò ìyá Délọdún tó wà ní Ìkérekú.
10. Àwọn ọlọ́pàá,
11. Ládépò àti àwọn ìyàwó rẹ̀, Àsùnlé àti Àtọ́kẹ̀ pẹ̀lú Olú ọmọ wọn.
12. Ìyá àgbà àti àwọn eléégún.
13. Àìsáyà Onígbogbonìṣe, bàbá ọdẹ àti ọmọ rẹ̀ Ògúngbàrò, ìyàwó bàbá ọdẹ kékeré.
14. Olúṣọlá, olúrántí àbúrò rẹ̀ pẹ̀lú ìyá wọn àti ẹ̀gbọ́n wọn tí wọ́n jọ wà ní ilé-ẹ̀kọ́.
15. Olùbẹ̀wò.

### Ọgbọ́n Ìsọ̀tàn

1. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ó-ṣojú-mi-kòró (first person narrative technique) Délọdún tó sọ ìtàn jé akópa, òun ni olú ẹ̀dá ìtàn.
2. Ọgbọ́n àlá. Délọdún lá àlà pé òun rí Àyọ̀ká tí ó ń kó ẹgba bo àfẹ́sọ́nà rẹ̀. Àlá náà wá sí ìmúṣẹ nígbà tí ọwọ́ àwọn ọlọ́pàá tẹ ọkọ àfẹ́sọ́nà náà tí wọ́n sì nà án bí i bàrà.
3. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn eré oníṣe. Òǹkọ̀wé lo ìlànà eré oníṣe (drama) nínú ìwé náà. Èyí wáyé nígbà tí Àkànmú àti Dọlápọ̀ ń fún ara wọn ní oríkì. Bákan náà nígbà tí àwọn ọlọ́pàá ń fi ọ̀rọ̀ wá ọkọ àfẹ́sọ́nà Àyọ̀ká lẹ́nu wò. Bákan náà nígbà tí Àtọ́kẹ̀ àti Olú ń bú ara wọn.
4. Ọgbọ́n ìsọ̀tàn ìtàn nínú ìtàn. Èyí wáyé nígbà tí àwọn ọmọdé ń pa àlọ́.

### Ibùdó Ìtàn

Ìtàn inú ìwé yìí wáyé ní abúlé Lábọ̀dé. Abúlé yìí ni Délọdún tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn gbé títí ó fi lọ sí ìlú Ìbàdàn. Púpọ̀ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé náà ló jẹ́ pé Lábọ̀dé tó ti ṣẹlẹ̀. Àkókò tí àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tẹ̀lé òbí wọn lọ sí ilé eégún ni ìtàn náà tún ṣí lọ sí Ìbàdàn. Ibùdó ìtàn mìíràn ni abúlé Olórìṣà nígbà tí ọkọ àfẹ́sọ́nà

Àyọ̀ká jí i gbé lọ. Bákan náà ni ìṣẹ̀lẹ̀ tún wáyé ní Ìkérekú nígbà tí ọwọ́ àwọn ọlọ́pàá tẹ ọkọ àfẹ́sọ́nà Àyọ̀ká tí wọ́n sì gbé e lọ sí Ìkérekú.

**Ìlò Èdè**

1. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́: ojú ewé 11, 17, 24
2. Òwe: ojú ewé 14, 33, 34
3. Àkànlò èdè: ojú ewé 5
4. Àlọ́ àpagbè: ojú ewé 14, 15
5. Ìfohunpènìyàn: Ojú ewé 17
6. Ọ̀rọ̀ àyálò: Ojú ewé 8
7. Ibéèrè pèsìjẹ: Ojú ewé 32, 34
8. Ọfọ̀: Ojú ewé 6
9. Àfiwé tààrà: Ojú ewé 9, 34

**Àṣà Yorùbá Tó Jẹyọ**

1. Òkú sísin: Èyí jẹyọ nígbà tí wọ́n ń sin òkú bàbá ọdẹ.
2. Àṣà oríkì orílẹ̀: Ojú ewé 109, 110
3. Oríkì ìnagijẹ: Ojú ewé 67
4. Eré ìdárayá / eré ọmọdé.
5. Ewí àti orin ọmọdé, orin àlọ́ àpagbè, orin etíyẹrí: Ojú ewé 26, 27, 28, 63, 64, 65, 66
6. Ọdún egúngún.
7. Àṣà fífi ọmọ lọ́kọ.

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Dárúkọ ọgbọ́n ìsọ̀tàn mẹ́ta tí òǹkọ̀wé lò nínú ìwé Ogún Ọmọdẹ́.
2. Dárúkọ ìlú márùn-ún tí òǹkọ̀wé mẹnubà nínú ìwé yìí.
3. Tọ́ka sí ìlò èdè mẹ́rin tí òǹkọ̀wé ṣe àmúlò nínú ìwé náà.

**Iṣẹ́ Àṣetilewá**

1. Ṣàlàyé ọdún egúngún bí ó ti jẹyọ nínú ìwé Ogún Ọmọdé.

**Ọ̀sẹ̀ Keje – Week 7**

**Ètò Òṣèlú Nílẹ̀ Yorùbá**

Ètó òṣèlú nílẹ̀ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ láti agboolé. Baálé ni olórí agboolé. Baálẹ̀ tàbí Mọ́gàjí ni olórí ìletò tàbí abúlé. Ọba ni olórí ìlú.

Ní ayé àtijọ́ inú agboolé kan ni gbogbo mọ̀lẹ́bí máa ń gbé. Ẹni tí ó dàgbà jù nínú ìdílé ni olórí ilé tí a ń pè ní baálé. Ìyàálé ni igbákejì rẹ̀. Nínú ilé ni a ti rí ọmọ ẹ̀gbọ́n àti ọmọ àbúrò.

Àwọn Ènìyàn nínú Ẹbí

1. Bàbá – father
2. Ìyá – mother
3. Ọmọ – child
4. Arákùnrin tàbí arábìnrin ẹni – sibling.
5. Ẹ̀gbọ́n – elder brother/sister.
6. Àbúrò – younger brother/sister.
7. Bàbá-bàbá – grand-father
8. Ìyá-ìyá – grand mother
9. Bàbá bàbá-bàbá – greate grand-father.
10. Ìyá ìyá-ìyá – greate grand-mother.
11. Àbúrò bàbá – uncle.
12. Àbúrò ìyá – aunt.
13. Ọmọ ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò – cousine
14. Ọmọkùnrin ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò – nephew
15. Ọmọbìnrin ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò – neice.
16. Ìyàwó bàbá ẹni – step mother.
17. Ọkọ ìyá ẹni – step father.
18. Ọmọ ọkọ ìyá tàbí ọmọ ìyàwó bàbá ẹni (ọbàkan)– step child

**OJÚṢE BAÁLÉ:** Òun ni olórí ilé. Lára ojúṣe rẹ̀ ni;

1. Ìjà pípari.
2. Àlejò gbígbà.
3. Lílé àlejò tí ó bá ṣẹ̀ kúrò ní agboolé.
4. Fífi ọmọ fọ́kọ àti fífẹ́ ìyàwó fún ọmọkùnrin.
5. Ètò ìnáwó ṣíṣe nínú ẹbí.
6. Mímójútó ọmọ ilé lọ́kùnrin àti lóbìnrin.
7. Ogún pípín.
8. Pípèsè ọmọ ogun ní àsìkò ogun.

**Ìyáálé**: Òun ni ìyàwó àkọ́kọ́ ti a kọ́kọ́ fẹ́ ní agboolé. Òun ni obìnrin tí ó dàgbà júlọ nínú ìdílé. Òun ni aṣojú àwọn obìnrin àti ọmọbìnrin ilé. Lára ojúṣe rẹ̀ ni;

1. Mímọ ìgbà tí a gbé ìyàwó, ìgbà tí a bí ọmọ àti ọjọ́ orí ọmọ kọ̀ọ̀kan.
2. Yíyanjú aáwọ̀ nípa ọjọ́ orí láàrin àwọn ọmọ
3. Yíyanjú ipò àgbà láàrin àwọn ìyàwó ilé.
4. Títọ́jú ìyàwó àṣẹ̀ṣẹ̀gbé.
5. Títọ́jú oyún àti aláboyún.
6. Ilà kíkọ àti abẹ dídá fún ọmọ titun.
7. Kíkọ́ àwọn ìyàwó ilé ní orìkì ìdílé.

**Ọkùnrin Ilé**: àwọn ni ọkùnrin tí wọ́n jẹ́ géńdé, tí wọ́n ti ní ìyàwó. Iṣẹ́ wọn ni;

1. Ilẹ̀ òkú gbígbẹ́ àti okú sísin.
2. Oko ilé ríro.
3. Ọ̀nà yíyẹ̀.
4. Ojú ogun lílọ.
5. Sísin ibi ọmọ sí balùwẹ̀.
6. Pípa ẹran níbi ìnáwó ilé àti ilé àna.

**Àwọn Obìnrin Ilé**: Àwọn ni obìnrin tí a gbé ní ìyàwó nínu agboolé. Ojúṣe wọn ni;

1. Wọ́n gbọ́dọ̀ máa bọ̀wọ̀ fún ìyáálé kí wọ́n sì pa ofin rẹ̀ mọ́.
2. Àwọn ni wọ́n máa ń dáná oúnjẹ ní àsìkò ọdún àti ayẹyẹ.
3. Wọ́n máa ń sun rárà níbi ìnáwó òkú ọkọ wọn.
4. Wọ́n máa ń tọjú ìyàwó àṣẹ̀ṣẹ̀gbé àti ìyàwó tó bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bímọ.

**Ọmọbìnrin Ilé**: Àwọn ni ọmọbìnrin tí kò tí ì lọ sí ilé ọkọ.

1. Wọ́n máa ń sin ìyàwó lọ sílé ọkọ rẹ̀.
2. Wọ́n máa ń kópa nínú orò ìdílé.
3. Wọ́n máa ń ran àwọn ìyàwó ilé lọ́wọ́ nínú iná dídá ni àsìkò ọdún tàbí ayẹyẹ.

**Àwọn ọmọ osú ilé / Adálémosú**: àwọn ni ọmọbìnrin ilé tí wọ́n ti lọ sí ilé ọkọ ṣùgbọ́n tí wọ́n tún wá ń padà gbé ilé bàbá wọn.

**Ètò Ìṣèlú Ìletò, Àdúgbò Tàbí Ìlú**

Ìletò, àdúgbò tàbí ìlú jẹ́ àpapọ̀ agboolé. Agboolé ló parapọ̀ di ìlú. Baálẹ̀ tàbí ìjòyè ni olórí ìletò tàbí àdúgbò. Ọba ni olórí ìlú.bí wọ́n ṣe ń yan baálẹ̀ tàbí ìjòyè yàtọ̀ sí bí wọ́n ṣe ń yan ọba ìlú. Ọba, aláṣẹ ìkejì òrìṣà, ni alákoso ìlú. Òun ló máa ń yan baálẹ̀ tàbí ìjòyè ìlú.

Àwọn afọbajẹ tàbí àwọn Ọ̀yọ́mèsì ló máa ń yan ọba ìlú. Ó ní àwọn ìgbésẹ̀ àti orò tí wọ́n máa ń ṣe kí wọ́n tó yan ọba ìlú. Ojúṣe baálẹ̀ àti ọba kò yàtọ̀ sí ara wọn. Lára ojúṣe wọn ni;

1. Ìdàgbàsókè ìlú.
2. Gbígba owó orí tàbí ìsákọ́lẹ̀.
3. Pípèsè ààbò láàrin ìlú.
4. Pípèsè ọmọ ogun ní àsìkò ogun.
5. Dídarí ẹ̀sìn ìbílẹ̀.
6. Yíyan àwọn ìjòyè sí ipò.
7. Pípari ìjà láàrin ìjòyè ìlú.
8. Pípari ìjà láàrin àdúgbò sí àdúgbò.
9. Ṣíṣe ojú ìlú nínú ìgbìmọ̀ lọbalọba.

**Àwọn Ìjòyè Ìlú: Oríṣi oyè ló wà.**

1. Oyè ìdílé
2. Oyè ẹ̀sìn
3. Oyè ogun
4. Oyè ìfidánilọlá.

1. **Oyè ìdílé**: Èyí jẹ́ oyè pàtàkì tí a jogún bá nínú ìdílé. Ó ní àwọn ìdílé tí ó máa ń jẹ irú oyè bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ oyè ìdílé ni; Òtún. Ọ̀ṣì, Ẹ̀kẹta, ẹkẹrin, ẹ̀karùn-ún àti ẹ̀kẹfà, Aṣípa, Ìyàlóde, Ìyálọ́jà, afọbajẹ, Ọ̀yọ́mèsì abbl.
2. **Oyè Ogun**, Ààrẹ-Ọ̀nà-Kakanfò, Balógun, Ọ̀tún Balógun, Òṣì Balógun, Ṣéríkí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
3. **Oyé ẹ̀sìn**: Apènà, Abọrẹ̀, Òsúgbó, Alágbàá.
4. **Oyè Ifidánilọ́lá**: Bóbagúnwà, Bọbajírò, Atúnlùúṣe, Amojúàṣà.

**Iṣé Kíláàsì**

1. Tọ́ka sí ojúṣe baálé márùn-ún tí o mọ̀.
2. Dárúkọ ènìyàn mẹ́wàá nínú ìdílé.

3. Tọ́ka sí oríṣi oyè mẹ́ta tí o mọ̀ pẹ̀lú àpẹẹrẹ kọ̀ọ̀kan.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Ta ni ọba ìlú?
2. Sàlàyé ojúṣe ọba ìlú márùn-ún tí o mọ̀.

## ỌSẸ̀ KẸJỌ – WEEK 8

## ÀRÒKỌ ONÍRÒYÌN

Èyí ni àròkọ tí alárọ̀kọ ti máa ń ròyìn ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹlẹ̀ lójú wọn. Alárọ̀kọ gbọ́dọ̀ sọ ọjọ́ tí ìṣẹ̀lẹ̀ náà Ṣẹlẹ̀, àsìkò tó ṣẹlẹ̀ àti ibi tí ó ti ṣẹlẹ̀. Bákan náà ni alárọ̀kọ gbọ́dọ̀ sọ ipa tí òun náà kó nínú ìṣẹ̀lẹ̀ náà.

**Àpẹẹrẹ Orí-Ọ̀rọ̀ Fún Àròkọ Oníròyìn**

1. Ìjàǹbá ọkọ̀ kan tó ṣojú mi
2. Ayẹyẹ ìgbéyàwó ẹ̀gbọ́n mi ọdún tó kọjá.
3. Ọdún egúngún ìlú mi ọdún tó kọjá.
4. Ètò ìpolongo ìbò ààrẹ ọdún tó kọjá.
5. Ìjà ìgboro àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó ṣojú mi.
6. Ayẹyẹ ọjọ́bìí mi ọdún tó kọjá.
7. Ayẹyẹ ìkẹ́kọ̀ọ́ jáde àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ọdún tó kọjá.

**Ìgbésẹ̀ Àròkọ Oníròyìn**

1. Orí-ọ̀rọ̀
2. Ìfáàrá
3. Kókó àròkọ
4. Ìkádìí / ìgúnlẹ̀

### Àpẹẹrẹ Àròkọ Oníròyìn

### <u>Ọdún Egúngún Ìlú Mi Ọdún Tó Kọjá</u>

Ọdún egúngún ní ìlú mi jẹ́ ọdún tí ó ṣe pàtàkì jùlọ. Tolórí tẹlẹ́mù, tọba àti ìjòyè ló máa ń péjú pésẹ̀ láti ṣe ọdún yìí. Ẹ̀ẹkan lọ́dún ní ọdún egúngún máa ń wáyé ní ìlú mi, ní ọ̀sẹ̀ àkọ́kọ́ nínú oṣù kẹjọ ọdún. Odidi ọ̀sẹ̀ méjì gbáko ni wọ́n fi máa ń ṣe é.

Tí ọdún tí mo ń ròyìn rẹ̀ yìí bùáyà, ó peléke. Bí ó ti ku oṣù kan kí ọdún eégún wọlé ni bàbá mi ti ń gé àtòrì ní ìmúrasílẹ̀ di ọdún eégún. Gbogbo àwọn ará abúlé ló ti ń múra sílẹ̀ fún ọdún náà. Ẹlòmírán ṣe èlùbọ́ tí wọn yóò lò ní àsìkò ọdún. Ẹlòmíràn yan gààrí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni wọ́n sá àgbàdo tí wọn yóò gbé lọ.

Ó ku ọjọ́ mẹ́ta ti eégún máa bẹ̀rẹ̀ ni èmi àti bàbá mi gbéra ó di ìlú wa, Ayétòrò. Ọdún Ògún ni wọ́n kọ́kọ́ ṣe kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ egúngún. Ní ọjọ́ tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ gan-an. Ọjà ni wọ́n kọ́kọ́ gbá, àwọn àgbà ọ̀jẹ̀ nínú eégún ló kọ́kọ́ jáde láti inú igbó ìgbàlẹ̀. Bí wọ́n ti ń jáde ni wọ́n ń forí balẹ̀ fún orí adé.

Onírúurú ọ̀bẹ làá rí lọ́jọ́ ikú erin. Oríṣìíríṣìí ni àwọn eégún tó jáde ní ọjọ́ náà. Bí a ti rí kúkurú ni a rí gígùn. Ère tó wà ní orí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn yàtọ̀ sí ara wọn. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí jó káàkiri ọjà. Àwọn eégún onídán naà kò mọ níwọ̀n. Bí wọ́n ti ń di ọká ni wọ́n ń di erè tí wọn ń di ọ̀bọ.

Ní ọjọ́ kejì ni àwọn eégún mìíràn bẹ̀rẹ̀ sí jáde pẹ̀lú onílù wọn. Lára wọn ni a ti rí Ọ̀gbàbú, Apẹ̀rẹ̀ Ìjàngbọ̀n, Alápáńsánpá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àwọn eléégún wọ̀nyí ti ń jó káàkiri ni àwọn ọmọlẹ́yìn wọn ń ja igbo. Ọrẹ́ àtòrì tí ẹlòmíràn rù fẹ́rẹ̀ tó ẹrù géńdé. Bí eégún méjì bá pàdé wọ́n á forí balẹ̀ fún ara wọn. Ìjà máa ń wáyé nígbà tí eégún mìíràn bá kọ̀ tí kò forí balẹ̀.

Apẹ̀rẹ̀ Ìjàngbọ̀n ni ìran rẹ̀ máa ń dùn ń wò. Bí ó ṣe jáde ní ọjọ́ yìí ni àwọn ọmọléyìn rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ja igbo tí wọ́n ń kó àtòrì bo ara wọn. Lójijì ni ọmọkùnrin gbọ̀ngbọ̀nràn ka báyìí jáde sí ààrin wọn, ó bẹ̀rẹ̀ sí kó ẹgba bo ẹnikẹ̀ni tí ó bá rí. Inú bí Apẹ̀rẹ̀ Ìjàngbọ̀n, ó pàṣẹ fún àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ láti dá sèríà fún ọkùnrin náa. Èyí mú kí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí lu ọkùnrin náà bí i kíkú bí i yíyè. Díẹ̀ ló kù kí ọmọkùnrin náà kú mọ́ wọn lọ́wọ́.

Ìròyìn kò tó àfojúbà ni ọdún eégún ti ọdún tí mo ń ròyìn rẹ̀ yìí, ẹni tó bá dé ibẹ̀ ó lè sọ. Bí ọdún eégún ṣe parí ni èmi àti bàbá mi tún padà sí abúlé wa. Gbogbo ohun tí ojú mi rí pátá ni mo ròyìn fún àwọn ọ̀rẹ́ mi tí wọn kò ní àǹfàní láti lọ sí ilé eégún.

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Ṣàlàyé àròkọ oníròyìn.
2. Tọ́ka sí ìgbésẹ̀ àròkọ oníròyìn.
3. Kọ àpẹẹrẹ orí-ọ̀rọ̀ àròkọ oníròyìn mẹ́ta sílẹ̀.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Kọ àròkọ tí kò dín ní 250 ẹyọ ọ̀rọ̀ lórí ọ̀kan nínú àwọn wọ̀nyí:
   a. Ayẹyẹ ìgbéyàwó ẹ̀gbọ́n mi tí ó wáyé láìpẹ́.
   b. Eré bọ́ọ̀lù aláfẹsẹ̀gbá tó ṣojú mi.
   c. Ìjà ìgboro àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ọdún tó kọjá.

## Ọ̀SẸ̀ KẸSÀN-ÁN: WEEK 9

## ÒWÒ ṢÍṢE ÀTI ÌPOLÓWÓ ỌJÀ.

Ìpolówó ọjà jẹ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà sọ fún àwọn ènìyàn nípa ọjà tí wọn ń tà. Irú ọjà bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ irè oko bi i àgbàdo, iṣu, ẹ̀gẹ́, òróǹbó, ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹ́wẹ́, ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà, ata rodo, ẹ̀gẹ́ tàbí gbágùúdá, ànàmọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó sì lè jẹ́ ọjà àtẹ bí i ìsáná, iyọ̀, àlùbọ́sà, ọṣẹ ìwé, epo pupa, bàtà, aṣọ, ẹní, irú, abọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Ọ̀nà Ìpolówó Ọjà Láyé Àtijọ́**

Ọ̀nà mẹ́ta ni àwọn Yorùbá ń gbà polówó ọjà láyé àtijọ́.

**1.Ìpàtẹ:-** Èyí ni kí á to ọjà sí ibi tí àwọn ènìyàn ti lè rí i tí wọn yóò sì fẹ́ láti ra irú ọjà bẹ́ẹ̀. Ọ̀nà mẹ́ta ni wọ́n máa ń pàtẹ ọjà sí láyé àtijọ́.

1. Ìpàtẹ ọjà sí ojú ọ̀nà:- Àwọn Yorùbá a máa pàtẹ ọjà sí ojú ọ̀nà láyé àtijọ́. Ojú ọ̀nà bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ń gbà lọ sí oko tàbí lọ sí ọjà. Bí wọ́n bá pàtẹ ọjà sí ojú ọ̀nà wọn a máa fi òkúta sọ iye tí wọ́n ń ta ìlé kọ̀ọ̀kan. Ẹni tí ó fẹ́ ra ọjà yóò kó ọjà tí ó rà yóò sì fi owó ọjà sínú agolo tàbí àpò. Bí ọlọ́jà bá dé ní ìrọ̀lẹ́ yóò kó owó rẹ̀ yóò sí palẹ̀ ọjà tó ṣékù mọ́.
2. Ìpàtẹ ọjà sínú ṣọ́ọ̀bù:- Àwọn Yorùbá a tún máa pàtẹ ọjà sínú ṣọ́ọ̀bù wọn. Irú ṣọ́ọ̀bù bẹ́ẹ̀ lè wà níwájú ilé. Ọjà oúnjẹ bí i ata, ẹ̀wà, ìrẹsì, àlùbọ́sà, magí, ẹja, pọ̀nmọ́, iyọ̀, epo-pupa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n sábà máa ń pàtẹ síwájum ilé.
3. Ìpàtẹ ọjà nínú ọjà:- Àwọn Yorùbá a máa pàtẹ ọjà wọn sí inú ọjà láyé àtijọ́. Irú ọjà bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ aṣọ, bàtà, ohun èlò ìdánà, ohun èlò ìkọ́lé, oríṣiríṣi oúnjẹ ằti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**2.Ìkiri:**- Èyí ni kí á gbé ọjà wa lé orí kí á sì máa lọ láti àdúgbò kan sí àdúgbò kejì láti fi ohùn ẹnu polówó ọjà tí a ń tà. Oríṣiríṣi ìpèdè ni àwọn tó ń kiri ọjà máa ń lò. Bí àpẹẹrẹ:

| Ọjà | Ìpolówó |
|---|---|
| Àgbàdo<br>Ẹ̀wà ṣíṣè<br>Iṣu sísè | Láńgbé jinná o.<br>Lámúlúkẹ̀ ẹ̀wà.<br>Iṣu epo mùyẹ̀. |

| | |
|---|---|
| Ẹja | Ẹ rẹja ẹ ṣebẹ̀ o. |
| Ẹ̀pà | Yééré rèé ẹ̀pà rèé. |
| Ìrẹsì | Ọ̀fẹ́ nìrẹsì ẹran lowó. |
| Kẹrosín | Àrọkún epo òyìnbó. |
| Ọ̀gẹ̀dẹ̀ | Èbó tòró ọ̀gẹ̀dẹ̀. |
| Òróǹbó | Oyin ladùn ọsàn o. |
| Iyán | Kengbe iyán o. |
| Àmàlà | Kengbe àmàlà. |
| Ẹ̀kọ jíjẹ | Oori bí ike |
| Ẹ̀bà | Kengbe ẹ̀bà. |
| Mọ́ín-mọ́ín. | Mọ́ín-mọ́ín epo ọ̀ọ̀lẹ̀ ròdò |
| Gààrí | Àyangbẹ gaàrí o. |
| Ilá | Ilá olóko gbọ̀rọ́ o |
| Awùsá | Awùsá yìí gbó keke bí obì.<br>Ó gbó o àgbólà.<br>Eléyín ní ń wá o kò wélérìgì.<br>Elérìgì abẹnu fìfo |

**3.Lílo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ láti polówó ọjà**:- Èyí jẹ́ ọgbọ́n tí àwọn ọlójà máa ń dá láti fa ojú oníbàárà mọ́ra. Àpẹẹrẹ ọgbọ́n ìpolówó ọjá ni:

**a. Ìtọ́wò**:- Èyí ni kí á tọ́ ọjà tí a fẹ́ rà wò kí á lè mọ̀ bí ó ṣe rí ní ẹnu kí á tó rà á. Àpẹẹrẹ ọjà tí a lè tọ́wò ni: ẹ̀pà, gààrí, òróǹbó, ẹmu, súyà, irú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**b. Ìsíwò**:- Èyí máa ń wáyé nígbà tí a bá ṣí ọjà tí a fẹ́ rà wò kí á lè mọ̀ bí ojú rẹ̀ ṣe dára sí. Irú ọjà bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ iyán, ẹ̀ba, àmàlà, mọ́ín-mọ́ín, ẹ̀kọ jíjẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**d. Ènì**:- Ènì jẹ́ ọjà díẹ̀ tí ọlọ́jà fi sí ọjà tí a rà lọ́wọ́ rẹ̀. Ó fẹ́rẹ̀ má sí ọjà tí wọn kò lè fi ènì sí pàápàá jùlọ bí ènìyàn bá ra ọjà púpọ̀. Àpẹẹrẹ ọjà tí wọ́n máa ń fi ènì sí ni gààrí, ìrẹsì, ẹ̀wà, ata, àlùbọ́sà, òrònbo, ẹ̀pà, àgbàdo, iyọ̀, irú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**e. Gbàǹjo**:- Gbàǹjo jẹ́ ọ̀nà tí wọ́n ń gbà ta ọjà ní owó pọ́ọ́kú. Wọn yóò da ọjà sílẹ̀ tí wọn yóò sì dín owó rẹ̀ kù.

**ÌPOLÓWÓ ỌJÀ LÁYÉ ÒDE ÒNÍ**

a. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn ènìyàn ń gbà polówó ọjà láyé òde òní. Díẹ̀ lára àwọn ọ̀nà náà ni;
b. Ìpolówó ọjà lórí rédíò
c. Ìpolówó ọjà lórí tẹlifísàn.
d. Ìpolówó ọjà nínú ìwé ìròyìn.
e. Ìpolówó ọjà lórí ẹ̀rọ ayélujára
f. Ìpolówó ọjà nípa lílo ìwé ìléwọ́
g. Ìpolówó ọjà nípa lílo àrokò ìkéde.
h. Ìpolówó ọjà nípa lílo ẹ̀rọ gbohùngbohùn
i. Ìpolówó ọjà nípa fífi ọkọ̀ tàbí alùpùpù kiri.
j. Ìpolówó ọjà nípa títa ráfùlù.
k. Ìpolówó ọjà nípa lílo ènì ìgbàlódé.
l. Ìpolówó ọjà nípa lílo bònáńsà

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Kí ni ìpolówó ọjà?
2. Dárúkọ ọ̀nà mẹ́ta pàtàkì tí àwọn Yorùbá ń gbà polówó ọjà wọn láyé àtijọ́.
3. Báwo ni a ṣe ń polówó ọjà wọ̀nyí?
   a. Àgbàdo
   b. Ẹ̀wà sísè.
   c. Ẹja yíyan.
   d. Ìrẹsì sísè
   e. Awùsá.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Tọ́ka sí ọ̀nà mẹ́ta tí àwọn Yorùbá ń gbà lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ láti ta ọjà wọn.

2. Dárúkọ ọ̀nà méwàá tí àwọn ènìyàn ń gbà polówó ọjà láyé òde òní.

## Ọ̀SẸ̀ KẸWÀÁ – WEEK 10

## Ọ̀RỌ̀-ÀYÁLỌ̀ (LOAN / BORROWED WORDS IN YORÙBÁ)

Ọ̀rọ̀-àyálò ni ọ̀rọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá láti inú èdè mìíràn. Oríṣiríṣi èdè ni èdè Yorùbá ti yá ọ̀rọ̀. Inú èdè tí wọ́n ti yá ọrọ̀ jù ni èdè Gẹ̀ẹ́sì nítorí pé èdè Gẹ̀ẹ́sì ni èdè àjùmọ̀lò orílẹ̀-èdè yìí.

**Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-àyálò àti èdè tí a ti yá wọn.**

1. Hausa : àlùbọ́sà, àlàáfíà, wàhálà, sánmọ̀, àlùbáríkà, gèjíà, kádàrá abbl.
2. Èdè Hébérù : Pítà, Bíbélì, sínágọ́gù, Áńdérù, Mòósè, Jòánù, párádísè abbl.
3. Èdè Lárúbáwá : Lèmọ́mù, yídì, mùsùlùmí, mọ́sálásí, mẹ́kà, abbl.
4. Èdè Gẹ̀ẹ́sì : tébù/ tábìlì, rọ́bà, péèlì, kámẹ́rà, bọ́tù, abbl

**Ọ̀nà Tí Ọ̀rọ̀-Àyálò Gbà Wọ Inú Èdè Yorùbá**

1. **È**tò òṣèlú : kọmísọ́nnà, wọ́ọ̀dù, gómìnà, sínétò, káńsẹ́lọ̀, káńsù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
2. Ètò ọrọ̀-ajé: àlùbọ́sà, túwó, sáábó, ìrèké, kálámù, jáárá, abbl.
3. Ètò-ẹ̀sìn : Bíbélì, pásítò, àlùkùráánì, lèmọ́mù, díákónì, ṣọ́ọ̀ṣì, Pétérù abbl
4. Ètò-ẹ̀kọ́ : sùkúù, báírò, pẹ́ńsù, ṣọ́ọ̀kì, tíṣà, bọ́ọ̀dù abbl
5. Eré ìdárayá : bọ́ọ̀lù, rẹfirí, golí, fíìdì, póòlù, tẹníìsì abbl
6. Ètò amúlùúdùn : kásẹ́ẹ̀tì, rẹ́kọ́ọ̀dù, tẹlifísàn, rédíò abbl

**ÌFARAMỌLÉ TÀBÍ ÒTÉ LÓRÍ Ọ̀RỌ̀-ÀYÁLÒ**

Òrọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú bátànì ìró èdè Yorùbá ní àwọn ọ̀nà wọ̀nyí:

1. Ọ̀rọ̀ tí a bá yá wọ inú èdè yorùbá kò gbọdọ̀ parí pẹ̀lú kọ́ńsónáńtì
2. Ọ̀rò tí a bá yá wọ inú èdè Yorùbá kò gbọdò ní ìṣùpọ̀ kọ́ńsónáńtì.
3. A gbọ́dọ̀ fi àmì ohùn sí orí gbogbo ọ̀rọ̀ tí a bá yá wọ inú èdè Yorùbá.
4. A gbọ́dọ̀ fi kọ́ńsónáńtì tàbí fáwẹ́lì èdè Yorùbá rọ́pò kọ́ńsónáńtì tàbí fáwẹ́lì ọ̀rọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá.

**ORÍṢI Ọ̀RỌ̀-ÀYÁLÒ**

A lè pín ọ̀rọ̀-àyálò sí ọ̀nà méjì nínú èdè Yorùbá.

1. Ọ̀rọ̀-Àyálò Afetíyá: Èyí ni ọ̀rọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá ní ìbámu pẹ̀lú bí wọ́n ṣe ń pe ọ̀rọ̀ náà nínú èdè tí a ti yá a.
2. Ọ̀rọ̀-Àyálò Afojúyá: Èyí ni ọ̀rọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá ní ìbámu pẹ̀lú bí wọ́n ṣe ń kọ ọ́ sílẹ̀ nínú èdè tí a ti yá a.

**Àpẹẹrẹ Ọ̀rọ̀-Àyálò**

| Ọ̀rọ̀-àyálò | Afetíyá | Afojúyá |
|---|---|---|
| Table | Tébù | Tábìlì |
| Bible | Báíbù | Bíbélì |
| Peter | Pítà | Pétérù |
| Esther | Ẹ́sítà | Esítérì |
| Deacon | Díkìnni | Díákónì |
| Paradise | Párádáìsì | Párádísè |
| Biro | Báírò | Bírò |

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Kí ní ọ̀rọ̀ àyálò?
2. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ méjì méjì, dárúkọ ọ̀nà márùn-ún tí ọ̀rọ̀-àyálò gbà wọ inú èdè Yorùbá.
3. Báwo ni a ṣe yá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí wọ inú èdè Yorùbá?
    a. Peter
    b. Ball
    c. Teacher
    d. Rubber
    e. Pencil

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Dárúkọ èdè mẹ́rin tí àwọn Yorùbá ti yá ọ̀rọ̀ lò.
2. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ méjì méjì, dárúkọ oríṣi ọ̀rọ̀-àyálò méjì tí o mọ̀.
3. Tọ́ka sí mẹ́ta nínú òté tàbí ìfinimọ̀lé lórí ọ̀rọ̀-àyálò.

**ỌSẸ̀ KỌKÀNLÁ – WEEK 11**

**Ọ̀RỌ̀-ÀGBÀSỌ – REPORTED SPEECH**

Èyí ni ọ̀rọ̀ tí a gbọ́ lẹ́nu ẹnìkan tí a tún sọ fún ẹlòmíràn. Irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó ti kọjá. Ọ̀rọ̀-àgbàsọ lè jẹ́ ohun tí ẹnìkan sọ nípa wa tàbí ẹlòmíràn. Ó sì lè jẹ́ ìròyìn ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ní ibì kan. A lè pín ọ̀rọ̀ àgbàsọ sí ọ̀nà méjì: afọ̀ aṣafọ̀ àti afọ̀ agbàrán.

**1. 1 AFỌ̀ AṢAFỌ̀ DIRECT SPEECH**

Afọ̀ Aṣafọ̀ ni ọ̀rọ̀ tí a sọ tààrà bí ọlọ́rọ̀ tàbí aṣafọ̀ ṣe sọ́ gan-an. Òhun ni a tún ń pè ní ọ̀rọ̀ ẹnu ọlọ́rọ̀. Nínú afọ̀ aṣafọ̀ ni a ti máa ń ri àmì wọ̀nyí:

a. Kọmá àyọlò ẹlẹ́yọ (‘ ’)
b. Kọmá àyọlò oníbejì (“ ”)
c. Kólọ́ọ̀nù ( : )
d. Àdàmọ̀di kólọ́ọ̀nù ( ; )

Bí àpẹẹrẹ:

“Ẹ bá mi ṣe iṣẹ́ yìí”

Adé: ‘N kò rí ìwé rà’

Àlàbá ni: “Mo lọ sí Èkó ní àná.”

**1. 2 AFỌ̀ AGBÀRÁN – INDIRECT SPEECH**

Afọ̀ Agbàrán ni gbígba ọ̀rọ̀ tàbí ìròyìn tí a gbọ́ láti ẹnu ọlọ́rọ̀ sọ fún ẹlòmíràn. Ìròyìn bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó ti kọjá. Àwọn atọ́ka afọ̀ agbàrán ni: sọ, wí, ni, kí, pàṣẹ, wi pe, ṣàlàyé, sọ fún, ní kí, pàṣẹ, bèèrè, lérí, ṣèlérí, gbàdúrà, abbl. Nínú afọ̀ agbàrán àyípadà máa ń dé bá ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ tàbí arọ́pò-afarajorúkọ.

**YÍYÍ AFỌ̀ AṢAFỌ̀ SÍ AFỌ̀ AGBÀRÁN**

| Afọ̀ Aṣafọ̀ | Afọ̀ Agbàrán |
|---|---|
| Jídé: N kò ní wá sí ìpàdé | Jídé ní òun kò ní wá sí ìpàdé. |
| Ṣọlá: Ṣé ẹ ti jẹun? | Ṣọlá bèèrè bóyá wón ti jẹun. |
| Mo fẹ́ lọ sí ọjà ní ọ̀la | Ó ní òun fẹ́ lọ sí ọjà ní ọ̀la. |

| | |
|---|---|
| Olùkọ́: Ẹ̀yin akẹ́kọ̀ọ́ ẹ dìde dúró. | Olùkọ́ pàṣẹ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dìde dúró. |
| Àjàyí: Adé,níbo ni o ti ń bọ̀? | Àjàyí bèèrè ibi tí Adé ti ń bọ̀. |
| Ó wù mí kí èmi náà ra ọkọ̀ titun. | Ó ní ó wu òun kí òun náà ra ọkọ̀ titun. |
| Kúnlé: Ebi ń pa mí. | Kúnlé sọ pé ebi ń pa òun. |
| Òjó: Mo ti jẹ iyán àti ọbẹ̀ ẹ̀fọ́. | Òjó ṣàlàyé pé òun ti jẹ iyán àti ọbẹ̀ ẹ̀fọ́. |
| Ayọ̀délé: N ó san owó tí mo jẹ Adé láìpẹ́. | Ayọ̀délé ṣèlérí láti san owó tí ó jẹ Adé láìpẹ́. |
| Mà á wá sí ìpàdé bí mo bá rí ìwé ìpè. | Ó wí pé òun yóò wá sí ìpàdé bí òun bá rí ìwé ìpè. |

**YÍYÍ AFỌ̀ AGBÀRÁN SÍ AFỌ̀ AṢAFỌ̀**

| Afọ̀ Agbàrán | Afọ̀ Aṣafọ̀ |
|---|---|
| Ó ní òun ti yo. | Mo ti yó. |
| Ìdòwú sọ wí pé òun kò le wá sí ibi  ìgbeyàwó náà. | Ìdòwú: N kò lè wá sí ibi ìgbeyàwó náà. |
| Wọ́n ní ebi ń pa àwọn. | Ebi ń pa wá. |
| Olùkọ́ jágbe mọ́ Jọkẹ́ kí ó kúrò níwájú òun. | Olùkọ́: Jọkẹ́, kúrò níwájú mi. |
| Wọ́n ṣàlàyé pé àwọn jẹun àmọ́ ebi tún ń pa àwọ́n. | A jẹun àmọ́ ebi tún ń pa wá. |
| Àjàyí sọ pé kò yẹ kí ọmọdé rí àgbà fín. | Àjàyí: Kò yẹ kí ọmọdé rí àgbà fín. |
| Kọmọláfẹ́ ní kí Olú wá rí òun bí ó bá ti ọjà dé. | Kọ́mọláfẹ́: Olú, wá rí mí bí o bá ti ọjà dé. |
| Mo fẹ́ lọ sí Èkó ní ọ̀la. | Ó ní òun fẹ́ lọ sí Èkó ní ọ̀la. |
| Àlàbá bèèrè pé kí ni wọ́n jẹ sùn lálẹ́ àná. | Àlàbá: Kí ni ẹ jẹ sùn lálẹ́ àná? |
| Olùkọ́ pàṣẹ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí wọ́n dákẹ́ ariwo. | Olùkọ́: Èyin akẹ́kọ̀ọ́ ẹ dákẹ́ ariwo. |

**Iṣẹ́ Kíláàsì**

1. Kí ni ọ̀rọ̀ àgbàsọ?
2. Dárúkọ orísi ọ̀rọ̀ àgbàsọ tí o mọ̀.
3. Yí afọ̀ aṣafọ̀ wọ̀nyí sí afọ̀ agbàrán
   a. Jídé: N kò jẹ àgbàdo.
   b. Àlàbí: Ebi ń pa mí.
   c. Mà á wá sí ìpàdé bí mob á rí ìwé ìpè.
   d. Mo ti jẹ iyán àti ọbẹ̀ ẹ̀fọ́.
   e. Kọ́mọláfẹ́: Jọkẹ, kúrò níwájú mi.

**Iṣẹ́ Àṣetiléwá**

1. Pẹ̀lúàpẹẹrẹ méjì méjì ṣàlàyé afọ̀ aṣafọ̀ àti afọ̀ agbàrán.
2. Yí afọ̀ agbàrán ìsàlẹ̀ yìí sí afọ̀ aṣafọ̀.
   a. Olùkọ́ jágbe mọ Àlàbá kí ó kúrò níwájú òun.
   b. Ó ní òun ti yó.
   c. Ìbùkún bèèrè ibi ti ọ̀nà ọjà wà.
   d. Àdùbí ni òun pa eku kan ní àná.
   e. Wọ́n ṣàlàyé pé àwọn jẹun ṣùgbọ́n ebi tún ń pa àwọn.

**ÀWỌN ÌBÉÈRÈ FÚN ÌDÁNRAWÒ (LIKELY EXAMINATION QUESTIONS)**

**YORUBA LANGUAGE SS 2 DURATION: 2 HOURS**

**SECTION A: OBJECTIVES**

**INSTRUCTION: ANSWER ALL QUESTIONS IN THIS SECTION.**

**Ka àyọkà ìsàlẹ̀ yìí kí o sì dáhùn ìbéèrè abẹ́ rẹ̀.**

Eré ìdárayá ṣe pàtàkì púpọ̀ nílẹ̀ Yorùbá. Ìrọ̀lẹ́, lẹ́yìn iṣẹ́ oòjọ́ tàbí nígbà tí ọwọ́ bá dilẹ̀ ni àwon Yorùbá máa ń ṣe eré ìdárayá. Oríṣi eré ìdárayá ló wà. Bí eré ojúmọmọ ṣe wà bẹ́ẹ̀ ni eré òṣùpá wà. Àwọn Yorùbá ní eré abẹ́lé, wọ́n sì ní eré ìta gbangba.

Àpẹẹrẹ eré ìdárayá ni bojú-bojú, ẹkùn mẹ́ẹ̀ran, ta ló wà nínú ọgbà̀ náà, kí ní ń lẹ́jẹ̀? Bọ́ọ̀kọ-bọ́ọ̀kọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. eré òṣùpá ni bojú-bojú. Ojúmọmọ ni àwọn Yorùbá máa ń ta ayò. Ènìyàn méjì ló ń ta ayò lẹ́ẹ̀kan. Ọmọ ayọ̀ méjìdínláàdọ́ta ló wà nínú ọpán ayò. Ọmọ ayò mẹrin ló máa ń wà nínú ihò kọ̀ọ̀kan. Ihò méjìlá ló máa ń wà nínú ọpọ́n ayò. Ihò mẹ́fà lápá ọ̀tún àti mẹ́fà lápá òṣì.

Apá ọ̀tún ni a máa ń ta ayò lọ. ènìyàn lè jẹ méjì tàbí mẹ́ta nínú ilé alátakò. A kò lé jẹ ayò nínú ilé ara ẹni. 'Mo kí ọ̀ta, mo kí òpè' jẹ́ ìkíni fún eré ayò. Ọ̀ta ni ẹni tí ó pa ayò. Òpè ni ẹni tí a pa láyò. Ẹni tí ó jẹ ayò tí ó pọ̀ jú nínú àwọn méjèèjì ló pa ayò.

Dáhùn ìbéèrè 1 – 10

1. _____ ṣe pàtàkì nílẹ̀ Yorùbá.
   A. Eré ìdárayá
   B. Eré ayò
   C. Eré òṣùpá
   D. Eré àrín
2. Àkókò tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe eré ìdárayá ní
   A. ìrọ̀lẹ́
   B. àárọ̀
   C. ọ̀sán
   D. ìyálẹ̀ta
3. Eré ojúmọmọ ni eré
   A. ayò
   B. bojú-bojú
   C. àlọ́ àpagbè
   D. àlọ́ àpamọ̀
4. Ènìyàn mélòó ló ń ta ayò lẹ́ẹ̀kan? Ènìyàn
   A. méjì
   B. mẹ́ta
   C. mẹ́rin
   D. márùn-ún
5. Gbogbo ọmọ ayò tó máa ń wà ní ojú ọpọ́n ayò jẹ́
   A. méjìdínlógún
   B. méjìdínlọ́gbọ̀n
   C. méjìdínlógójì
   D. méjìdínláàdọ́ta
6. Iye ihò tó máa ń wà nínú ọpọ́n ayò jẹ́
   A. mẹ́wàá
   B. mọ́kànlá
   C. méjìlá
   D. mẹ́tàlá
7. Ọmọ ayò ____ ló máa ń wà nínú ihò kan.
   A. méjì
   B. mẹ́ta
   C. mẹ́rin
   D. márùn-ún
8. Ìkíni fún eré ayò ni
   A. Mo kí ọ̀ta, mo kí òpè.
   B. Ẹ káàárọ̀
   C. Ó dàárọ̀
   D. Ẹ kú iṣẹ́
9. Ẹni tí a pa láyò ni a ń pè ní
   A. ọ̀ta

B. òpè
C. ọ̀lẹ
D. àbúrò

10. Ọwọ́ ___ ni a máa ń ta ayò lọ.
A. òṣì
B. ọ̀tún
C. ìsàlẹ̀
D. òkè

ÀRÒKỌ – COMPOSITION

11. "Mo fara mọ́ ọn, n kò fara mọ́ ọn". máa ń jẹyọ nínú àròkọ
A. alárìíyànjiyàn
B. aláláyé
C. onísọ̀rọ̀gbèsì
D. alápèjúwe

12. Nínú àròkọ wo ni a ti máa ń ròyìn ìṣẹ̀lẹ̀ tó kọjá?
A. Aláláyé
B. Ajẹmọ́-ìṣípayá
C. Oníròyìn
D. Alápèjúwe

13. Àròkọ tó máa ń ní àdírẹ́sì ni
A. lẹ́tà kíkọ
B. àròkọ oníròyìn
C. àròkọ aláláyé
D. onísọ̀rọ̀gbèsì

14. "Ọmọkùnrin dára ju ọmọbìnrin lọ" jẹ́ àpẹẹrẹ àròkọ
A. alárìíyànjiyàn
B. onísọ̀rọ̀gbèsì
C. alápèjúwe
D. aláláye

15. A lè pín lẹ́tà kíkọ sí ọ̀nà
A. kan
B. méjì
C. mẹ́ta
D. mẹ́rin

**Ètò Ìró àti Gírámà**

16. Kọ́ṇsónáńtì àfèjìètè pè ni
A. /b/
B. /r/
C. /g/
D. /m/

17. Èwo ni kọ́ńsónáńtì aránmú?
A. /s/
B. /p/
C. /m/
D. /d/

18. Kọ́ńsónáńtì aránmú aṣesílébù ni
A. /t/
B. /p/
C. /n/
D. /s/

19. Àfipè àkànmọ́lẹ̀ ni àwọn wọ̀nyí **àyàfi**
A. Ètè òkè
B. eyín òkè
C. èrìgì òkè
D. eyín ìsàlẹ̀

20. Organ of speech ni
A. eyín
B. ẹsẹ̀
C. ọwọ́
D. orúnkún

21. Fáwẹ́lì ni àwọn wọ̀nyí **àyàfi**
A. /a/
B. /b/
C. /r/
D. /s/

22. Kọ́ńsónáńtì èdè Yorùbá jẹ́
A. méjìdínlógún
B. mẹ́rìnlá
C. méjìlá
D. mẹ́wàá

23. Ọ̀rọ̀-orúkọ nínú "Mo ra ọ̀gẹ̀dẹ̀ pípọ́n jẹ" ni
A. pípọ́n
B. jẹ
C. ọ̀gẹ̀dẹ̀
D. mo

24. Nínú, “Adé wá àmọ́ a kò ríra” ọ̀rọ̀-àsopọ̀ ni
A. adé
B. àmọ́
C. ríra
D. wá

25. Nínú, “Ewúrẹ́ jẹ àgbàdo náà” ọ̀rọ̀-orúkọ tó ṣiṣẹ́ olùwà ni
A. àgbàdo
B. ewúrẹ́
C. náà
D. jẹ

26. Tọ́ka sí orúkọ-aṣeékà nínú àwọn wọ̀nyí.
A. omi
B. epo
C. ọ̀rá
D. tábìlì

27. Adé jẹ ẹja dídín. Ọ̀rọ̀-àpèjúwe nínú gbólóhùn yìí ni
A. jẹ
B. adé
C. dídín
D. ẹja

28. Gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe ni gbólóhùn tó ní ọ̀rọ̀-ìṣe
A. kan
B. méjì
C. mẹ́ta
D. mẹ́rin

29. Kọ́lá jẹ èbà pẹ̀lú ẹran ìgbẹ́. Ọ̀rọ̀-àsopọ̀ nínú gbólóhùn yìí ni
A. pẹ̀lú
B. ẹ̀bà
C. ẹran
D. kọ́lá

30. Nínú, “Kúnlé kọ́ ilé tí ó tóbi”, olórí awẹ́ gbólóhùn ni
A. Kúnlé kọ́ ilé
B. Kọ́ ilé tí
C. tí ó tóbi
D. kọ́ ilé tí ó tóbi

31. Ọ̀rọ̀-ìṣe nínú, “Àjàlá gun igi gíga”, ni
A. gùn
B. gíga
C. Àjàlá
D. Igi

32. Wọ́n ra aṣọ àti bàtà titun. Ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ nínú gbólóhùn yìí ni
A. rà
B. aṣọ
C. wọ́n
D. bàtà

33. Ọ̀rọ̀ tó ṣíṣẹ àbọ̀ nínú, “Àdìṣá fẹ́ràn ẹmu funfun”, ni
A. fẹ́ràn
B. ẹmu funfun
C. funfun
D. Àdìṣá

34. Nínú, “Kò yẹ kí ọmọdé rí àgbà fín”, awẹ́ gbólóhùn afarahẹ ni
A. Kò yẹ
B. rí àgbà fín
C. kí ọmọdé rí àgbà fín
D. kò yẹ kí ọmọdé

35. Ẹ̀yán nínú, ‘Ìyá Bọ́lá bí ọmọ titun” ni
A. Bọ́lá
B. ìyá
C. titun
D. ọmọ

36. Ọ̀rọ̀-ìṣe mélòó ló wà nínú “Jídé gbé ẹja lọ sí ọjà”?
A. méjì
B. mẹ́tá
C. mẹ́rin
D. márùn-ún

37. Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé máa ń yán ọ̀rọ̀
A. ìṣe
B. orúkọ
C. àpèjúwe
D. àsopọ̀

38. Nínú, “Ilé wa kò jìnnà púpọ̀” ọ̀rọ̀-àrọ́pò-orúkọ ni
A. kò
B. wa
C. ilé
D. jìnnà

39. Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ wo ni “fẹ́ràn” nínú, “Adé fẹ́ràn eré òṣùpá”? Ọ̀rọ̀
A. orúkọ
B. ìṣe
C. àpèjúwe
D. atọ́kùn

40. Ọ̀rọ̀-atọ́kùn ni àwọn wọ̀nyí **àyàfi**
A. sí
B. tí
C. ní
D. àti

**Àṣà - Culture**

41. Eré ìdárayá òde òní nínú àwọn wọ̀nyí ni
A. lúdò
B. bọ́ọ̀kọ-bọ́ọ̀kọ
C. eré ayò
D. ẹkùn mẹ́ẹ̀ran

42. Èwo ni eré ìdárayá abẹ́lẹ́ nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Ẹkẹ tàbí ìjàkadì
B. Bojú-bojú
C. Ẹkún mẹ́ẹ̀ran
D. Eré ayọ̀

43. Èwo lọ́ jẹ́ mo àṣà ìsìnkú nínú àwọn wọ̀nyí?
A. Ìlẹ̀pa òkú
B. Ẹkún-ìyàwó
C. Àrokodóko
D. Orúkọ àbísọ

44. Adìrẹ tí a fi ń ra ọ̀nà fún òkú tí a ń gbé láti oko bọ̀ wá sí ilé ni
A. adìrẹ ìrànà
B. ajá ọdẹ
C. ìyá ewúrẹ́
D. abo ẹlẹ́dẹ̀

45. Òkú tí wọ́n máa ń sin sí etí odò ni òkú ẹni tó kú
A. sínú odò
B. ìdí igi
C. ìdí ọ̀pẹ
D. ilé ìwòsàn

46. Olórí ilé ni àwọn Yorùbá ń pè ni ___
A. baálé
B. ọba
C. ìjòyè
D. ọdẹ

47. Igbákejì baálé nílẹ̀ Yorùbá ni __
A. baálé
B. ìyáálé
C. ọmọbìnrin ilé
D. ọmọkùnrin ilé

48. Olórí ìlú nílẹ̀ Yorùbá ni __
A. oba
B. bale
C. bale
D. ijoye

49. Èwo nínú àwọn oúnjẹ wọ̀nyí ni kò sí nínú àṣà Yorùbá?
A. Àmàlà àti gbẹ̀gìrì
B. Iyán pẹ̀lú ọbẹ̀ ẹ̀gúsí
C. Ègbo pẹ̀lú ẹ̀wà rírò
D. Túwó àti másà

50. Iṣẹ́ abínibí nínú àwọn wọ̀nyí ni iṣẹ́
A. olùkọ́
B. àgbẹ̀
C. lọ́yà
D. dókítà

**Lírírẹ́ṣọ̀ – Literature**

51. “Ilé làá wò, ká tó sọmọ lórúkọ” jẹ́ àpẹẹrẹ
A. òwe
B. orin
C. àlọ́ àpamọ̀
D. ọfọ̀

52. Àlọ́ àpagbè Yorùbá sábà máa ń dálé orí

A. ọ̀bọ
B. ìjàpá
C. ewúrẹ́
D. ajá

53. Òrìṣà tó ni ṣàngó-pípè ni
A. Ṣàngó
B. Ọya
C. Ọ̀ṣun
D. Orò

54. Ọ̀jẹ̀lárìnnàká jẹyọ nínú ìwé
A. Eégún Aláré
B. Omi Inú Ẹkù
C. Mọrèmi Àjàṣorò
D. Ta ló pa ọmọ ọba

55. Ìyàwó Ọ̀jẹ̀lárìnnàká ni
A. Ìyádùnńní
B. Dáṣọfúnjó
C. Lárìnnàká
D. Ọ̀jẹ́làdé

**Ìtumọ̀ – Translation**

56. Wálé ate yam and stew.
A. Wálé lọ sí ọjà
B. Wálé jẹ iṣu àti ọbẹ̀ ata
C. Wálé mu omi
D. Wálé ń ka ìwé

57. Kọ́láwọlé is a student.
A. Akẹ́kọ̀ọ́ ni Kọ́láwọlé.
B. Ọba ni Kọ́láwọlé.
C. Kọ́láwọlé gun igi.
D. Òjò pa Kọ́láwọlé

58. She fell down.
A. Ó jókòó.
B. Ó dìde
C. Ó ṣubú
D. Ó ń jó.

59. Come here.
A. Wá níbí.
B. Kúrò níbẹ̀
C. Dìde dúró.
D. Jáde síta.

60. Read your book.
A. Mo fẹ́ rí ọ
B. Ka ìwé rẹ
C. Jẹ oúnjẹ rẹ.
D. Olùkọ́ ń pè ọ́.

## SECTION B:THEORY

## INSTRUCTION: ANSWER FIVE (5) QUESTIONS IN THIS SECTION

1. Kọ àròkọ lórí ọ̀kan nínú àwọn orí-ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:
   a. Ilé-ẹ̀kọ́ mi
   b. Oúnjẹ tí mo fẹ́ràn jú.
   c. Ọmọkùnrin wúlò ju ọmọbìnrin lọ
   d. Kọ lẹ́tà sí ọ̀rẹ́ rẹ tí ó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ mìíràn kí o ṣàlàyé fún un nípa àwọn nǹkan mẹ́ta tí ó ń jẹ ilé-ẹ̀kọ́ rẹ níyà.
2. Kọ àpẹẹrẹ méjì méjì fún ọ̀kọ̀ọ̀kan gbólóhùn wọ̀nyí:
   a. Gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe
   b. Gbólóhùn alákànpọ̀
   c. Gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ ìṣe
   d. Gbólóhùn àṣẹ.
3. Tọ́ka sí olórí awẹ́ gbólóhùn àti awẹ́ gbólóhùn afarahẹ nínú gbólóhùn wọ̀nyí:
   a. Ìdòwú kọ́ ilé tí ó tóbi.
   b. Àlàbá pọn omi tí ó fẹ́ mu.
   c. Àyànfẹ́ á wá sí ìpàdé bí ó bá rí ìwé ìpè.
   d. Kọ́lá fẹ́ jẹun bí ó bá ṣe tán.
   e. Wọ́n lọ sí ọjà kí òjò tó rọ̀.
4. (i) Kọ fáwẹ́lì àìránmúpè àti fáwẹ́lì aránmúpè èdè Yorùbá sílẹ̀.
   (ii) Fa ìlà sí ọ̀rọ̀-ìṣe nínú gbólóhùn wọ̀nyí:
   a. Àjọké gun igi.
   b. Ìyábọ̀ pọn ọmọ rẹ̀.
   c. Wọ́n sáré lọ sí ìlú Ìbàdàn.
   d. Àjàyí pàdé wa ní ilé-ẹ̀kọ́.
   e. A jẹ àmàlà pẹ̀lú ọbẹ̀ gbẹ̀gìrì.
5. (i) Dárúkọ eré ìdárayá márùn-ún ní èdè Yorùbá.
   (ii) Dárúkọ ènìyàn márùn-ún nínú ìdílé.
6. (i) Ṣàlàyé ohun tó fà á tí Ọ̀jẹ̀ Lárìnnàká fi pinnu látí lọ pidán ní ìlú mìíràn.
   (ii) Kọ orúkọ ẹ̀dá ìtàn márùn-ún sílẹ̀ nínú ìwé **Eégún Aláré**.

`